# Ọba Náà Tí Wọ́n Kọ̀

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Karundinlogun, Oṣu Karun, 1960

1 … a ń fojú sọ́nà fún ògo Olúwa kí ó sọkàlẹ̀ sórí wá lóní nípasẹ̀ ìwàásù Ọ̀rọ̀ náà. Ojú-ọjọ́ kò fararọ fún mi ní ọ̀sẹ̀ tí ó kọjá yìí, kìí ṣe wípé ojú-ọjọ́ ní pàtó, ó jẹ́ àyẹ̀wò kan tí mo ní láti ṣe, àyẹ̀wò ti ará. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ nìyìí nígbà tí ẹ gbọ́ wípé mo wà ní ilé-iwosan. Èrèdí ni wí pé mo lọ sí ibẹ̀ láti sinmi kí ó má jẹ́ wí pé ń o máa lọ, máa bọ̀ nígbà gbogbo ní ìkọjá odò. Bí wọ́n ṣe ń ṣe àyẹ̀wò ohun tí ó wà nínú ìfun ńlá wò, niwọ́n ń yẹ ti ìfun kékèké wò láti ìgbàdégbà ni wọ́n sì ń fi ẹ̀rọ ya àwòrán rẹ̀.

Ṣùgbọ́n a ní láti ṣe àyẹ̀wò wọ̀nyí, tí a bá ní láti ṣe iṣẹ́ ìhinrere ní Òkè-Òkun, ní oṣù mẹ́fà-mẹ́fà. Arákùnrin Roberts àti àwọn yókù, mo rò pé wọn a máa ṣe àyẹ̀wò tiwọn ní oṣù mẹ́fà-mẹ́fà, ṣùgbọ́n èmi kò tíì ṣe ọ̀kan láti ọdún mẹ́rin sẹ́yìn.

2 Ìṣòro ti ó wà níbẹ̀-ń kò fẹ́ràn òróró ilárà, ohun kan ṣoṣo náà nìyí. Wọ́n sì wípé kò sí ohun mìíràn tí wọ́n lè fún mi dípò rẹ̀, nítorí náà, mo… Ah! o wá rẹ̀ mí nígbàtí wọn fún mi ní òróró ilárà náà. Ṣè bí ẹ mọ̀ wípé, mo ti sọ fún yín nínú ìtàn ìgbésí ayé mi bí ohun náà ṣe máa nmu mí ṣe àìsàn púpọ̀, mo sì kórira láti gbàá. Mo sì wá wí fún dókítà dáradára náà ẹni tíí ṣe ọ̀rẹ́ mi wípé, kò há sí ohun mìíràn bíi?"

O si wipe, "Emi ko ro bẹẹ, Arakunrin Branham."

3 Ah, nígbà tí omidan náà wọlé wá tí ó dàbíi…bóyá mo ń sọ àsọdùn, ṣùgbọ́n ó dàbí ẹnití wọ́n pín sí mẹ́rin. Èmi kò tii rí irú rẹ̀ rí. N ò sì fi ọwọ́ dí imú mi, ṣùgbọ́n mo ríi gbé mì pátápátá.

Ṣùgbọ́n nínú gbogbo ìdánwò náà, ohun gbogbo lọ pẹ̀lú ìrọ̀rùn, mo fẹ́ dúpẹ́ lọ́wọ́ Olùwa fún àyẹ̀wò pípé. Mo yege ní ọ̀nà ọ̀gọ́rùn-ún, mo lè lọ sí ibikíbi ní gbogbo àgbáyé tí mo bá fẹ́ lọ. Mo bi àwọn dókítà léèrè -tii ṣe mẹ́ta tí ó dárajù nínú àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́, bí mo ṣe mọ, ni Louisville-mo sì bi wọ́n léèrè wípé, "Ǹjẹ́ mo ṣe àìlera nií ìdámẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún bí?".

Ó wípé, "O kò tilẹ̀ ṣe aláìlera bó ti wù kó mọ". Ó wípe "Ara rẹ dá ṣáṣá ní gbogbo ọ̀nà". Mo sì dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run. Ọ̀dọ̀ tani èyí lè tiwá wípé kí n wà ní ìlera pípé bí kò ṣe Baba wa tí ń bẹ ní ọ̀run. Ó sì wípé; "gbogbo iṣàn ara rẹ fi hàn wípé ọ̀dọ́ ṣì tún ni ọ́" ó wípé, "gbogbo àwọn ẹyin-ẹ̀jẹ̀ rẹ kò tíi bẹ̀rẹ̀ sí ní bọ rẹ̀lẹ̀". Ó wípé, "Arákùnrin Branham, ìrí rẹ dára púpọ̀"

Mo sì wí pé "inú mi dùn púpọ̀".

4 Mo sì ní àǹfààní láti sọ̀rọ̀, tí mo ń jẹ́rí sí gbogbo àwọn Nọ́ọ̀sì àti àwọn dókítà ní ilé-ìṣègùn náà fún ijọba Ọlọ́run. Dókítà kan, ẹnití morò wípé ó yẹ kí ó wàní ibiyí ní òwúrọ̀ yìí. Inú mi dùn láti mọ̀ wípé àwọn eniyan rere sì tún wà nínú ayé yìí, àwọn ẹni rere san-an, àwọn ẹni tí wọ́n ṣe ayẹwò fún mi fún odidi ọjọ́ márùn-ún, èyí tí iye owó rẹ̀ ṣeéṣe kí ó jẹ́ igba tàbí ọ̀ọ́dúnrún owó-dọ́là (USD) fún ẹyọ àyẹ̀wò kan; nígbà tí mo ṣe tán, wọ́n wá sọ wípé, "Èyí ni atilẹyin tiwa fún iṣẹ́ Olúwà tí ó ń ṣe." Wọ́n sì wípé, "sa ti gbàdúrà fún wa".

"Nínú rẹ" wọn wí fún mi pé, "a rí ohun ìtara kan tí kò yé wa." Wọ́n wípé "ko dà bí ẹni pé…" ó wípé; "Ni òde-ara, o kò ní àìfọ̀kànbalẹ̀ tàbí ìdàámú, ṣùgbọ́n nínú rẹ ìtara kan wa tí kò yé wa".

Mo sì wí fún wọn pé; "Ti ẹyin yóò bá farabalẹ̀ nibíyí fún ìgbà díẹ̀, èmi yóò sọ fún yín". Mo sì bẹ̀rẹ̀ sí níí sọ nípa àwọn ìran, ó jẹ́ ohun tí ó yàtọ̀ sí wọn, wọ́n kò mọ ohun kan nípa rẹ̀. Mo sọ fún wọn nípa Bíbélì. Mo wá sọ fún wọn nípa ìran tí Olúwa fi fún mi ní ọjọ́ kan, wọn sì sunkún bíi ọmọdé - wọ́n kan jókó wọn sì sunkún.

Mo sì wí wọn pé; mo lérò wípé ẹ kò kà mí sí ẹni tí ó gba wèrè mọ́ ẹ̀sìn.

5 Wọn wípé "Rárá o, Arákùnrin Branham. Mo gba èyí gbọ́ pẹ̀lú gbogbo ọkan mi." ó wá sọ wípé, ṣùgbọ́n ohun kan ni mo fẹ́ sọ, o kò lọ sí ilé-ìwé láti kọ́ àwọn ohun wọ̀nyí", mo gbàgbọ́ wípé láti ọdọ̀ Ọlọ́run Olódùmarè ni ó ti wá. Àwọn wọ̀nyí sì jẹ́ àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ oníṣègùn mẹ́ta pàtàkì ní Louisville, àwọn tí ó dára jùlọ tí wọn ni. Nítorí náà, inú mi dùn púpọ̀ fún èyí àti wípé mo mọ̀ pé bóyá Olùwa jẹ́ kí ń lè gbin àwọn irúgbìn díẹ̀ níbẹ̀.

6 Gbogbo àwọn Nọ́ọ̀sì ni mo bá sọ̀rọ̀… Ní òwúrọ̀ ọjọ́ kan, mo ń bọ̀ láti inú iyara ẹ̀rọ ayàwòrán, mo wá sọ fún… Mo rí ìyá arúgbó kan, ó ṣe àìsàn tó bẹ́ẹ̀ gẹ. Mo sì bẹ̀rẹ̀ sí ní rìn lọ títí mo fi dé ọdọ̀ rẹ̀. mo rò wípé ó tilẹ̀ ń kú lọ, mo sì wí pé "mo fẹ́ bi ọ́ ní ìbéèrè kan, arábìnrin".

Ó dáhùn pé, "ó dára, alàgbà?"

Mo sì wípé, "Njẹ́ Kristẹni ni ọ́ bí?"

Ó sì dáhùn wípé, "Mo jẹ ti ọmọ ijọ kan báyí".

Mo sì wípé, "Mo kàn fẹ́ ṣe àlàyé èyí síi". Mo sì wípé,

“Mo fẹ́ mọ̀ bóyá Kristẹni ni ọ́, Kristẹni ni tòótọ́. Wípé ti o ba tilẹ̀ rékọjá lórí odò ayé yìí sí ilẹ̀ míràn, ṣe o fẹ́ràn Rẹ̀?” Mo wi fún pé, “Njẹ a ó gbà ọ́ là bí?”

O sì wí pé, “Bẹ́ẹ̀ ni, alàgbà, ń o di ẹni ìgbàlà”.

Mo wa wípé, “ki Ọlọ́run bukun ọkan rẹ nígbà náà, ibikibi ti atẹ́gùn ba ń fẹ̀ sí, o ti dára fún ọ nìyẹn, níwọn ìgbà tí ó bá rí bẹ́ẹ̀”. Tí a bá sì rìn kiri, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èniyàn dáradára si tún wà lórí ilẹ ayé.

7 Nisisiyi, lóní yi mo ti wá pẹ̀lú ìran kan tí n o sọ́ fún yín nígbà tí ó bá yà. Tí n o si fẹ sọ̀rọ̀ ní àkọ́kọ́ ni orí ọ̀rọ̀ náà, Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ni pàtàkì, ohun ni pàtàkì jù báyìí.

8 Inú mi sì dùn láti rí Charlie Cox àti Arákùnrin…. Àwọn ọ̀rẹ́ mi tí wọ́n dúró ní ibiyí papọ̀-Arakùnrin…N kò lè ronú… Jefferies (Èmi kò lè ronú orúkọ rẹ), ọpọ̀lọpọ̀ ẹyin ará iyèbíye láti Georgia wá, láti orísìrísí ibi gbogbo ní orílẹ̀-èdè. Ọ̀rẹ́ mi àtijọ́ Bill tí ó jókó ní ibiyí (mo gbàgbọ́ wípé bẹ́ẹ̀ni) ní òwúrọ̀ yìí, àti ọpọ̀lọpọ̀…àti Arákùnrin láti Georgia níbẹ̀yẹn, àwọn eniyan tí wọ́n fún mi ní ẹ̀wù àwọ̀lékè-pẹ̀lú ṣòkòtò tí mo ti wọ̀ rí. Ó dára púpọ̀. O ti dára jù… Mo gba tiyín púpọ̀. Nígbà tí mo bá sọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí mi ni àwọn ọjọ́ wọ̀nyí, ẹ o rí èrèdí tí mo fi sọ wípé ó ní ìtúmọ̀ símì púpọ̀.

9 Nísisiyi, mo gbàgbọ́ pé tí Olúwa bá fẹ́, mo fẹ́ tẹ ogun náà síwájú sí ní takun-takun ju bí mo ti ṣe láti àtẹ̀yìnwá nínú ayé mi, nítorí wípé mo ti rí nísisiyi… dájúdájú, Mo lè kú lónìí. Èyí… ìwọ gan kòmọ̀. Awọn iná tí ó wà ní ọkàn eniyan àti bẹ́ẹ̀ lọ, àwòrán mẹ́rindinlógún ti wọ́n ya fún mi nípa ẹrọ fi hàn wípé gágá lára mi dá gẹ́gẹ́ bí ti ẹlòmíràn ṣe rí pèlú, gẹ́gẹ́ bí eniyan lórí ilẹ̀ ayé. Nítorí náà, mo dúpẹ́ fún èyí, ṣùgbọ́n ohun gbogbo, àní nínú ohun gbogbo, àti bí mo ṣe lè dúpẹ́ tó tí mo sì mọ ore Ọlọ́run tó pẹ̀lú ìgbàgbọ́ wípé O sì tún pa mímọ́ nínú iṣẹ́ ìsìn Rẹ̀, kì í ṣe ohun tí ó fi hàn mi ní ìgbà díẹ̀ ṣáájú àkókò náà, ṣe ẹ ríi. Ó kan mú inú mi dùn ni.

10 Nisisiyi, mo rò wípé ni alẹ́ yìí… ó dára bẹ́ẹ̀, tàbí bẹ́ẹ̀kọ́? Arákùnrin wa ọ̀wọ́n jẹ́ eniyan tí kìí ṣe onímọ̀-tara-ẹni ọkùnrin, bẹ́ẹ̀ni Arákùnrin Neville jẹ́. Tí ẹnikẹ́ni nínú yín bá sì wà níbíyìí ní ọjọ́ Àìkú tí ó kọjá tí ó sì gbọ́ iṣẹ́-ìránṣẹ́ àgbààyanu tí ó wàásù rẹ̀, “Kólóbó Òróró Náà”, ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́-ìránṣẹ́ àgbààyanu tí mo ti gbọ́ rí, ohun ni Arákùnrin Neville mú wá nípa Ẹ̀mí Mímọ́ ní ọjọ́ Àìkú tí ó kọjá fún àwọn agbo àgùntàn kékeré yìí tí Ọlọ́run ti kó jọ. Tí yóò bá sì dára bẹ́ẹ̀, tí yóò sì wu Olúwa, pẹ̀lú Arákùnrin Neville àti ìjọ, Mo fẹ́ sọ̀rọ̀ lẹ́ẹ̀kan sí ní alẹ́ yìí, tí a ó sì bẹ̀rẹ̀ àwọn àkójọpọ̀ ìwàásù kan, bíi alẹ́ ọjọ́ Ajé, ọjọ́ Àìkú ni mo fẹ sọ àti alẹ́ ọjọ́rú, àti ọjọ́ Àìkú tó ńbọ̀- àkójọpọ̀ ohun tí mo ti ṣe àṣàrò lé lórí.

11 Èmi kò bá ti dúró ní ilé-ìṣègùn náà ṣùgbọ́n wọ́n dára púpọ̀ sí mi. Wọ́n fún mi ní iyàrá náà ní ìdákan nínú ìdásímẹ́ta owó tó yẹ kí wọ́n ó gbà, nítorí náà, mo kan mú Bíbélì mi, àwọn ìwé mi, mo sì palẹ̀ ìbùsùn náà mọ́, mo sì jókó pẹ̀lú ìfarabàlẹ̀, tí mo sì to Bíbélì mi àti ohun gbogbo kalẹ̀, mo gbádùn rẹ̀ púpọ̀- àyàfi ìgbà tí wọ́n mú òróró-ìlárà náà dé. Àkókò ìgbádùn tí mo ń ní sì dópin ní bẹ́ẹ̀; ó parí fúnní wàyí. Ṣùgbọ́n Arákùnrin Pat, mo ṣe àìsàn púpọ̀púpọ̀. Ohun yẹn gan ni n kò fẹ́. Ṣùgbọ́n mo ń gbádùn ọjọ́ mẹ́ta tàbí mẹ́rin ìṣáájú.

Mo ń ní àkókò tó dùn, mo sì ń ṣe àṣàrò nínú ìwé àwọn ará Efésù. Ah! bí ìjọ ṣe ti wà, mo rò pé ohun tí ó dára ni.

12 Nísisiyi, tí o bá ní ìjọ tí o ń lọ, lọ sí ibẹ̀ kí o sì ṣe ojúṣe rẹ, ṣùgbọ́n tí o kò bá ní ìjọ kankan , tí o sì fẹ́ láti padà wá sí ibiyí ní alẹ́ yìí àti alẹ́ ọjọ́ru àti alẹ́ ọjọ́ Àìkú, N o fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ní alẹ́ yìí pẹ̀lú ìwé akọ́kọ́ ti Efésù, àti ní alẹ́ ọjọ́rú orí kejì ti Efésù, àti ní ọjọ́ Àìkú tí ó ńbọ̀, orí ìkẹta ti Efésù, láti gbé ijọ̀ kalẹ̀ létò. Ṣé ohun tí mo sọ yé yín-ó jẹ́ gbígbé eniyan kalẹ̀ sí ipò, mo sì rò wípé ó jẹ́ ìgbéga fún ijọ.

Nísisiyi, ǹ ko…Mo ń ba àwọn tí o n wa sì Ilé-Ìjọ́sìn agọ Branham sọ̀rọ̀. Ti ẹnikẹ́ni nínú ẹyin Ara mi ọ̀wọ́n… Mo mọ̀ díẹ̀ nínú yín, mo rò pé àwọn tí ó ní àwọn ìpàdé, Àwọn Arákùnrin wa kékeré tí wọ́n wà ní ìlú Sellersburg àti àwọn míràn tí wọ́n ní àwọn ìpàdé. Nísisiyi, ẹ kíyèsí, àwọn ìpàdé ìsọjí wọnnì. Ẹ le lọ sí ibẹ̀, àwọn ìránṣẹ́ Kristì ni wọ́n-àwọn ọdọ́mọkùnrin tí wọ́n dúró ní ibi àyè náà, wọ́n ti jáde wá. Nígbà tí ijọ̀ wọn ti ṣẹ́ òtítọ́ náà àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ, wọ́n rìn kúrò ní ibẹ̀, Ọlọ́run sì pè wọ́n sí inú iṣẹ́-ìránṣẹ́.

13 Bẹ́ẹ̀ni, alàgbà, mo ní ìfẹ́ sí àwọn eniyan… N kò tilẹ̀ rántí orúkọ ọkùnrin náà. Ṣùgbọ́n ọ̀dọ́ ni, ẹni rere, ẹni tó dùn ní wíwò àti ìyàwó rẹ pẹ̀lú àwọn ọmọ.

Arákùnrin Junie Jackson sì ti ṣe àwọn ìpàdé ni ibẹ̀ wọ̀nyẹn, ẹni tíí ṣe ẹni ìyanu, ẹni ẹyẹ pàtàkì ti oore-ọ̀fẹ́ iyanu ti Ọlọ́run.

Tí wọ́n bá sì ń ṣe àwọn ìsọjí ní àwọn ilé-ìjọsìn yín, ẹ lọ sí ibẹ̀ tàaràtà nitorí pé ohun tí ó yẹ láti ṣe ni, nítorí o kò mọ-ẹlẹ́sẹ̀ kan lè wá sí ibi pẹpẹ, ó sì lè ní iṣapá láti darí eniyan bẹ́ẹ̀ sí ọ̀dọ̀ Kristì, èyí tí yóò jẹ́ èrè ńlá fún un ní òkè lọ́hún. Èyí jẹ́ ikọ́ni ní ibiyí tí a ó sì gbé ijọ kalẹ̀ létò nínú Àgọ́ ní ibiyí, tí yóò jẹ́ ìrànlọ́wọ́ bí a ti ṣe ńtẹ̀síwájù.

14 Nísisiyi, N ko mú agogo ọwọ́ mi wá, kí ẹnikan bá mi kíyèsíi agogo. Doc. ti fi han wípé oun ní agogo kan

lọ́wọ́… (Arákùnrin Branham ba Arákùnrin rẹ sọ̀rọ̀ kẹ́lẹ́-Arákùnrin rẹ, Doc).

15 Nisisiyi, N kò ní sọ̀rọ̀ fún ìgbà pípẹ́. Nísisiyi, tí àlèjò bá wà ní ẹnu-bodè wa, a fẹ́ láti kí yín káàbọ̀ pẹ̀lú gbogbo ọkàn wa. Ẹ káàbọ̀ púpọ̀-púpọ̀ nínú Àgọ́ wa kékeré yìí, a kò ní ilé-ìjọ́sìn tí ó tóbi. Ó ti wà nínú ètò láti kọ́ ilé-ìjọ́sìn fún ara wa ní ibiyí èyí tí yóò rọ̀ wá lọ́rùn tí Ọlọ́run bá fi àyè gbà wá. Ọpọ̀lọpọ̀ yín ni ó sì ti ń lọ́wọ́ síi, a sì mọ rírì yín.

16 Nísisiyi, n o fẹ́ kí ẹ ṣí ìwé mímọ́ yín ní òwúrọ̀ láti ka, Samúẹ́lì Kìnní, orí kẹjọ, kí a bẹ̀rẹ̀ láti….. Ẹ jẹ́ kí a bẹ̀rẹ̀ láti ẹsẹ ìkọkàndínlógún, àwọn ẹsẹ ìkọkàndínlógún àti ogún, bóyá, fún àkòrí fún kókó ọ̀rọ̀. bí ẹ ti ṣe ń ṣí nísisiyi àti kí…A tó kaa, a fẹ́ láti gbàdúrà; ǹ jẹ́ ẹbẹ̀ àdúrà há wà ní òwúrọ̀ yìí, ǹjẹ́ ìwọ wípé, “Rántí mi?”

17 Ninú àwọn… ọsẹ méjì tàbí mẹta sẹ́yìn nígbàtí mo ṣe ìpàdé…Mo fẹ́ sọ èyí nígbà tí ẹ ṣì ìwé Mímọ́ lọ́wọ́ wípé, àwọn ìpàdé yóò bẹ̀rẹ̀ ní Chantaqua ní ọjọ́ kẹfà, a ń fojúsọ́nà fún àkókò ńlá-ní Middletown, Ohio.ẹyin tí àkókò ìsìnmi yín tí ń bọ̀ lójú ọ̀nà, ẹ wá síbẹ̀. Ìpàgọ́ ńlá lẹ́bá òdò, níbití gbogbo ìwáásù ti ẹ ti lẹ lè gbọ́ gbé wà. Gbogbo wọn wà nísàlẹ̀ àti lókè, àwọn oníwàásù ní gbogbo òwúrọ̀, ní gbogbo ọ̀sán àti alẹ́. Níbẹ̀ ni gbogbo eniyan gbé kórajọpọ si. Ó jẹ́ ilẹ̀ ìpàgọ́ ńlá. Ó tóbi púpọ̀ ju ìpàgọ́ àwọn Òkè-Fàdákà lọ (Silver Hills Campground)- lọpọ̀lọpọ̀- ó jẹ́ ibi tí ó tóbi tí ó lè gba àwọn eniyan bíi ẹgbẹ̀rún-mẹ́jọ sí ẹgbẹrún-mẹ́wá, ó sì má ń kún púpọ̀. A máa ń ní àkókò ńlá ní Ohio.

18 Àti àgbàlagbà Arákùnrin Kidd, tí mo lọ gbàdúrà fún ní òwúrọ̀ ọjọ́ kan-gbogbo yín rántí nígbà tí mo sọ fún yín ní ọ̀sẹ̀ mẹ́ta sẹ́yìn, dókítà fún ni wákàtí mẹ́rìn-lélógún síi láti fi wà lórí ilẹ̀ ayé-òun ni ó ti dide tí ó sì ń rìn kiri yìí o. O wá ka àkọ́sórí ìwé-Mímọ́ kan, orin kan tí kò lè kọ. Nígbà tí mo sì wọlé láti wòó ní òwúrọ̀ ọjọ́ náà, pẹ̀lú aṣọ ìbora kékeré tí ó fi bora…Mo kúrò ní ibiyí ní nkan bíi wákàtí mẹ́ta sí mẹ́rin kí ilẹ̀ tó mọ́ kí nba lè dé ọ̀dọ̀ rẹ, wọn sọ wípé ọjọ́ náà ni yóò kú-jẹjẹrẹ-ìṣẹ̀tọ̀.

19 Àti ìyàwó rẹ iyebíye ẹni tí ó jẹ́ àgbàlágbà a sì máa ṣe iṣẹ́ àgbàfọ̀ aṣọ fún àádọ́ta senti (ìdajì owó dọ́là kan) ní ojúmọ. Èyí sì jású wípé yóò ti bẹ̀rẹ̀ láti ìdájí títí di alẹ́ fún àádọ́tà senti (ìdajì owó dọ́là kan) kí ọkọ̀ rẹ̀ sì lè wà lorí pápá ìhinrere gẹ́gẹ́bí oníwàásù. Nígbà tí ó bá sì ti wàásù ìsọjí fún ọ̀sẹ̀ méjì tí wọ́n bá sì gba owó-ọrẹ, àròpọ̀ gbogbo rẹ̀ a sì jású ọgọ́rin senti (80c). Sùgbọ́n mo wá rí tí wọ́n jókòó ní ibẹ̀yẹn ní òwúrọ̀ ọjọ́ kan-àwọn méjèèjì àgbàlagbà tọkọ-taya (tàbí àwọn tọkọ-taya kékeré) tí wọ́n jókòó ni ibẹ̀, pẹ̀lú aṣọ ìbora kékeré rẹ̀ ní èjìká rẹ, àti ọkan nínú àwọn tí ó jèrè fún Kristì ẹni ọdún méjì-lé-láàá-dọ́rún-un, tí ó sì ń dán mèremére tí ó sì ń tàn, onígbàgbọ́ Pentikọ́stì tọkàn-tọkàn, tí ó jókó ní ibẹyẹn, ṣé ẹ mọ̀

Mo sì wípé; “Ẹ̀yin, kínni ẹ̀yin àgbàlagbà eniyan ń jókó níbíyìí fún?”

“A ń dúró fún ọkọ-ojú omi náà láti dé”.

Gbogbo iṣẹ́ wọn, gbogbo ohun tí wọ́n ti ṣe, eròńgbà kan tí wọn ti mú ṣe, wọ́n sì ti wá ṣetán báyìí láti lọ sí ibi èrè wọn. Mo sì wá wí fún Arákùnrin Kidd ní òwúrọ̀ ọjọ́ náà pé; “ìwọ yóò wa ni ibi ìpàde Chautauqua”.

Lana ni ó pé mí tí ó sì wípé, “N o wà níbẹ̀ Arákùnrin Branham”. Ó sì wá dárá bẹ́ẹ̀.

20 Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn… ìpàdé bẹ̀rẹ̀ láti inú iṣẹ́-ìránṣẹ́ mi titun tí ó nbọ̀. Arákùnrin Ijọ Onitẹbọmi kan ti o duro nibi yi - ọmọbinrin rẹ̀, ó jẹ́ ọdọ́, ó ti ń ṣàkó lọ, mo sì wí fún pé, “Mo fi ọmọbìnrin rẹ fún ọ fún Jesu Olúwa”, ní òwúrọ̀ ọjọ́ kéjì tí ó lọ sí ilé a sì gba ọmọbìnrin rẹ là, òmíràn sì wà ní ibíyí ní òwúrọ̀ yìí fún ìtẹ̀bọmi, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.

Ọkùnrinan kan, Ọ̀gbẹ́ni Sothmann, ọrẹ́ mi láti Canada-ìyá-ìyàwó rẹ̀, tí ó ń kú lọ, mo wí fún pé; “ìwọ yóò bá ìyá-ìyàwó rẹ̀ tí ara rẹ yóò máa yá nígbà tí o bá dé ibẹ̀”. Bẹ́ẹ̀ náà ni ó sì rí. Àwọn eniyan ń wọlé wá. Ó sì wà ní èwe rẹ báyìí, tí ó n dàgbà ṣùgbọ́n a ń fojúsọ́nà fún èyí tí jẹ́ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ju gbogbo rẹ lọ. Awà ni àwọn ọjọ́ ìkẹyìn tí ó sì burú, ṣùgbọ́n ní wákàtí tí ó lógo.

21 Nísisiyi, ǹjẹ́ ẹ gbé Bíbélì yín fún kíkà?... Orí kẹjọ ti Samuelì, mo sì ti ṣe ìlérí fún Gene wípé n o dúró níbi ẹ̀rọ tí ó ń gba ohun sílẹ̀, fún gbogbo èyí… a ṣẹ̀ṣẹ̀ ń bẹ̀rẹ̀ ìpàdé wa ni.

Ṣùgbọ́n àwọn eniyan náà kọ̀ láti gbọ́ ohùn Samuelì, wọ́n sì wípé bẹ́ẹ̀kọ́, àwa ò ní ọba lórí wa; Aní àwa ò sì…. dàbí gbogbo àwọn orílẹ̀-èdè;

Kí ọba wa sì máa ṣe ìdájọ́ wa, kí ó sì máa ṣáájú wa, kí ó sì máa jagun wa.

Samueli sì gbọ́ gbogbo ọ̀rọ̀ àwọn eniyan náà, ó sì sọ wọ́n ni etí Olúwa.

Olúwa sì wí fún Samueli pé, gbọ́ ohùn wọn kí o sì fi ọba jẹ fún wọn. Samueli sọ fún àwọn ọmọ Israeli pé, lọ olúkulukù sí ìlú rẹ̀.

Nísisiyi, tí n o bá mú ohun kan láti ibiyí ní òwúrọ̀ yìí tí n o pe ní àkòrí ọ̀rọ̀ fún ìṣẹ́jú díẹ̀, n o fẹ́ láti yan àkòrí-ọ̀rọ̀, “Ọba Náà Tí Wọ́n Kọ̀”.

22 Ó jẹ́ àkókò kan, gẹ́gẹ́bí ní gbogbo àwọn àkókò, àwọn eniyan kìí fẹ́ kí Ọlọ́rùn máa darí wọn. Wọn fẹ́ ìdárí ní ọnà ti ara wọn. Ati ìtàn yìí ni owúrọ yìí (Ti ẹ bá dé ilé yín, yóò dára ti ẹ ba le ka gbogbo rẹ), o jẹ́ ni àkókò ìgbà ayé Samuelì, eniyan Ọlọ́run, wòlíì náà, ó sì ti jẹ́ olódodo ọkùnrin àti ọkùnrin rere-ọlọ́lá, olókìkí, olótítọ́, tí ó sì ní ìwà funfun pẹ̀lú àwọn eniyan, kìí tàn wọ́n jẹ́, kìí sì sọ ohunkóhun fún wọn ṣùgbọ́n “Báyìí ni Olúwa wi”.

23 Ṣùgbọ́n àwọn eniyan tí wá dé ààyè ibikan ní ibi tí wọ́n sì fẹ láti yí èto yìí padà. Wọn tí wo àwọn ará Filistini àti àwọn ará Amalékì, àwọn Hiti, àti àwọn orílẹ̀-èdè ayé, wọ́n sì ti rí wípé wọn ní àwọn ọba tí ó darí wọn, tí ó ṣe àkóso wọn, tí ó ń tọ wọn, tí ó jagun fún wọn, àti bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ. O sì wá dàbí ẹni wípé Israelì náà sì fẹ́ ṣe àwòkọ́ṣe àwọn ọba àti àwọn eniyan wọ́nyí.

Ṣùgbọ́n kò tii ṣẹlẹ̀ rí ní ìran kan, wípé kí Ọlọ́run ní ìpinnu fún àwọn eniyan Rẹ̀ láti hùwà bí àwọn eniyan ayé, tàbí kí a darí wọn, tàbí ṣe àkóso wọn gẹ́gẹ́ bí àwọn eniyan ayé. Àwọn eniyan tí Ọlọ́run jẹ́ eniyan ọ̀tọ̀ nígbà gbogbo, àwọn eniyan tí ó yàtọ̀, àwọn tí a pè jáde, tí a ya sọ́tọ̀, tí wọ́n sì yàtọ̀ pátápátá nínú ìṣe wọn nínú àwọn ọ̀nà wọn, nínú ìgbé-ayé wọn, sí ohun tí àwọn eniyan ayé ni. Ìfẹ́ wọn àti gbogbo ìṣẹ̀dá wọn ni, ó sì ti ń máa tako gbogbo ohun tí àwọn eniyan ayé ń fẹ́.

24 Àwọn eniyan Israeli sì tọ Samuel wá, wọ́n sì wípé; “Nísisiyi, ìwọ ń dàgbà, àwọn ọmọ rẹ kò sì rin ní ọ̀nà rẹ̀”, nítorí pé wọn kò ṣe olótítọ́ gẹ́gẹ́ bí Samuel. Wọ́n a máa gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ àti owó lọ́wọ́ àwọn eniyan. Wọ́n sì wípé, “Samuel, àwọn ọmọkùnrin rẹ kò dàbí ìwọ. Nitori náà, a fẹ́ kí ó jáde lọ láti wá ọba kan fún wa, kí o sì fi oróró yàn-án, kí a sì dàbí àwọn eniyan ayé gbogbo”.

Samuel si gbìyànjú láti sọ fún wọn wípé kòlè dara bẹ́ẹ̀. Ó sọ wípé, “Ti ẹ bá ṣe èyí nnì, ohun àkọ́kọ́ ni wípé, yóò kó gbogbo àwọn ọmọkùnrin jọ láti ilé yín wá, yóò sì sọ wọ́n di àwọn ọmọ-ogun láti máa sáré níwájú àwọn kẹ̀kẹ́-ẹṣin rẹ̀, wọn ò sì má kó ìhámọ́ra àti ọ̀kọ̀ rẹ. Kìí ṣe èyí nìkan, yóò pe àwọn ọmọbìnrin láti máa ṣe àkàrà fún, yóò sì kó wọn lọ láti máa bọ́ àwọn ọmọ-ogun.” Ó sì wípé, “Yàtọ̀ sí gbogbo èyí, yóò má gba owó-ori lọ́wọ́ yín, tí àwọn ohun ọ̀gbìn yin, àti àwọn owó ọ̀yà yín. Yóò gbé owó lórí gbogbo ìwọ̀nyí kí ó fi lè san gbogbo gbèsè ijọba àti àwọn ohun tí ó jẹ́ láti san”. Ó sọ wípé ẹ ti ń ṣe àṣìṣe“.

Ṣùgbọ́n nígbà tí…àwọn eniyan sọ wípé; “Ṣùgbọ́n a sì fẹ́ láti dàbí àwọn eniyan gbogbo”.

25 Ohun kan wà tí àwọn ọkùnrin àti àwọn obìnrin a máa fẹ́ láti dàbí ẹlòmíràn. Ẹnìkan ṣoṣo ni ó sì ti gbé orí-ilẹ̀ ayé tí ó jẹ́ apẹẹrẹ fún wà: Oun náà ni ẹnití ó kú fún gbogbo wa, Olúwa àti Olùgbàlà wa Jesu Kristi. O jẹ́ àpẹẹrẹ pípé ohun tí ó yẹ kí a jẹ́ - A máa ṣe iṣẹ́ Baba nígbà gbogbo àti èyí tí ó tọ́.

26 Bí ó sì ti wù kí Samuel pa àrọwà sí àwọn eniyan tó, lemọ́lemọ́ ni wọ́n n wá sọ́dọ̀ rẹ̀ lọ́sán àti lóru. “A fẹ́ ọba kan, a fẹ́ ẹnìkan, a fẹ́ ọkùnrin kan ti a le sọ wípé, ”Èyí ni amọ̀nà wa“ Èyí kò sì ti jẹ́ ìfẹ́ Ọlọ́run. Kìí ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run tẹ́lẹ̀ rí, tàbí kò sì lè jẹ́ ìfẹ́ Ọlọ́run wípé kí eniyan máa darí eniyan ẹlẹgbẹ́ rẹ̀. Ọlọ́run ni máa ń darí eniyan, Ọlọ́run ni olórí, Ọba wa. Ọ̀rọ̀ náà si dàbí tí òní nítorí eniyan sì tún ní irú èrò bẹ́ẹ̀. Wọn kò le gbà wípé Ọlọ́run ni ó n darí eniyan, dípò kí eniyan máa dárí eniyan.

Nígbànáà, wọ́n wá yan ọkùnrin kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Sáùlù fún ara wọn, ẹni tí í ṣe ọmọ Kíṣìì. Ó sì jẹ́ olókìkí eniyan, ọlọ́lá eniyan, ṣùgbọ́n ó dọ́gba pẹ̀lú àwọn eniyan nítorípé ó jẹ́ ẹni ńlá, tí ó ga, tí ó sì gbọ́-afẹ́. Ìwé mímọ́ sọ wípé ó ga ju gbogbo àwọn eniyan lọ ní Ísráẹ̀lì láti èjìká rẹ̀ lọ sí òkè. Ó dùn wò gẹ́gẹ́ bí ọba, ó jẹ́ arẹwà, ó jẹ́ ẹni tí ó ní ìmọ̀ tí ó sì jẹ́ ẹ̀dá tí ko wọ̀pọ̀.

27 Nísisiyi, irú ẹnití àwọn eniyan fẹ́ láti yan lóni nìyí. Ó dàbí ẹni pé kò tẹ́ àwọn eniyan lọ́run bíi Ọlọ́run ti ṣe gbé ìdarí ìjọ Rẹ̀ kalẹ̀ àti àkóso láti ọwọ́ Ẹmi Mímọ́ wa. Wọ́n ń fẹ́ ẹnìkan, ọkùnrin kan, ìjọ-ádámọ̀ kan, àwọn eniyan ọ̀tọ̀ kan láti máa darí ìjọ, wọn kò sì le fi ara wọn jì fún Ọlórun pátápátá kí wọ́n lè wà nínú Ẹ̀mí, kí Ẹ̀mí Mímọ́ le máa darí wọn. Wọ́n fẹ́ ki ẹlòmíràn máa ṣe ẹ̀sìn wọn fún wọn, ẹni tí yóò máa sọ bí wọn yóò ti ṣee àti ohun gbogbo nípa rẹ̀, nítorí náà ọkùnrin yìí wa dọ́gba pẹ̀lú ìfẹ wọn, nítorí pé ó jẹ́ ọlọgbọ́n eniyan.

Bákan náà ni ó sì ti rí lónìí, a fẹ́ láti yan irúfẹ́ àwọn eniyan bẹ́ẹ̀ láti darí àwọn ìjọ wa, láti darí ìjọ Ọlọ́run. N kò ní ohun kan láti sọ tako èyí, ṣùgbọ́n láti pe àkíyèsí, kò yẹ kò rí bẹ́ẹ̀, kò rí bẹ́ẹ̀ tẹ́lẹ̀, láyéláyé kò sì lè jẹ́ ìfẹ́ Ọlọ́run wípé kí irú rẹ̀ ṣẹlẹ̀. Ọlọ́run ló ní láti darí àwọn eniyan Rẹ̀, láti máa ṣe àkóso olúkúlùkù.

28 A sì wá rí wípé ọmọ Kíṣìì yi - ẹni ńlá, àti ìrí rẹ̀, ó dà bí ẹni pé ó bá àwọn eniyan dọ́gba, wípé aṣọ yóò dùn wò lára rẹ̀ àti adé lórí rẹ̀ - tí ó ga ju gbogbo àwọn eniyan lọ láti èjìká rẹ̀ sókè bíi ó ti ṣe n rin- yóò jẹ́ dúkìá lótítọ́ fún ìjọba Israeli, nítorí pé àwọn ọba àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn yóò rò wípé, “Ẹ wò ó, irú ọkùnrin wo nìyí!” Bí wọ́n ti ṣe le máa na ìka wọn láti wípé, “Ẹ wo o, irú ọba tí a ní! Ẹ wo irú ẹni ńlá tí ó ń jọba lórí wa!”

Ó bani nínú jẹ́ la sọ èyí, ṣùgbọ́n bí ọ̀rọ̀ ìjọ ti ṣe rí lóni nìyí. Wọ́n fẹ́ láti sọ wípé, “Olùsọ́-àgùntàn wa kìí ṣe elérò-kúkurú eniyan; ẹni ńlá ni, ó ti kàwé-gboyè ni Harvard tàbí ilé ẹ̀kọ́ Bíbélì ńlá, ó ti kàwé-gboyè mẹ́rin ni àwọn ilé-ẹ̀kọ́ báyibayi, ó sì jẹ́ aláwọ̀ṣe tí ó dára laarin àwọn eniyan. Gbogbo àwọn ǹkan wọ̀nyí le dára kí wọn sì ni ipò ti wọn, ṣùgbọ́n ọ̀nà Ọlọ́run fún ìjọ Rẹ̀ ni wípé kí a máa darí rẹ̀ láti ọwọ́ Ẹ̀mí-Mímọ́ àti nípa Ẹ̀mí Rẹ̀. Ṣùgbọ́n wọn fẹ́ran láti sọ wípé, ”A ni ìjọ-àdámọ̀ ńlá yìí tí ó jẹ́ ti wa. A ti bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà àwọn aṣáájú nígbàtí a wa

ni kéréje, àwọn eniyan tí kò pọ̀ tí ó sì kéré. A ti nisisiyi a sì ti dàgbà dé ibi pé àwa náà ti wà láàrín awọn ìjọ-àdámọ̀ tí ó tóbi púpọ̀. A ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí ó dárajùlọ àti àwọn oníwàásù tí wọ́n kàwé jùlọ. A ní àwọn ọmọ-ìjọ tí ó mọ aṣọ wọ jùlọ àti àwọn tí o gbọ́n jùlọ nínú ìlú ni wọn wa si ilé-ìjọsìn ìjọ-àdámọ̀ wa. A sì máa n ṣe ìtọrẹ-àánú, a sì máa n soore àti irú bẹ́ẹ̀". Kò sì sí ohun kan….. Ọlọ́run ma jẹ́ kí n rí ohun tí n o fi sọ̀rọ̀ tako èyí, nítorí pé gbogbo rẹ̀ ni ó dára o; ṣùgbọ́n síbẹ̀ kìí ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run ni wípé ki eniyan máa jẹ́gàba lórí eniyan.

29 Ọlọ́run ran Ẹ̀mí Mímọ́ lọ́jọ́ Pentekosti láti máa ṣe àkóso lórí ọkàn àwọn eniyan àti lórí ayé rẹ̀. Kí iṣe eniyan ni o yẹ láti máa darí eniyan.

Ṣùgbọ́n a fẹ́ láti sọ bẹ́ẹ̀, ó jẹ́ ohun ńlá nígbà tí a bá le sọ wípé a jẹ́ ti àjọ ńlá. Ǹjẹ́ Kìrìsìtẹ́nì ni ọ́ bí? Bí mo ṣe rí àkòrí-ọ̀rọ̀ yìí ni yi. Nígbàtí mo wa ni ilé ìṣègùn, n o béèrè lọ́wọ́ ẹnìkan, "Ǹ jẹ́ Kìrìsìtẹ́nì ni ọbí?" "Mo jẹ́ ti ìjọ báyìí báyìí."

"Ǹjẹ́ Kìrìsìtẹ́nì ni ọ́ bí?"

"Mo jẹ ti bayi, bayi."

Nọ́ọ̀sì kékeré náà si wọlé wá sí ẹ̀gbẹ́ ìbùsùn níbití mo ti ń ka Bíbélì, ó sì jẹ́ nọ́ọ̀sì titun ní ibẹ̀, ó sì sọ wípé, "Báwo ni ó ṣe wa?" Ó sọ wípé, Mo gbàgbọ́ pé ìwò ni ẹni-ọ̀wọ̀ Branham tí ó wá sí ibi yìí fún àyẹ̀wò ara."

Mo si dáhùn pé, "Èmi ni."

Ó wípé, "Ǹ jẹ́ mo lè bá ọ ra ẹ̀yìn rẹ̀ pẹ̀lú ọtí-líle (ògógóró) ki ara rẹ̀ fi lè ya gágá?"

Mo sì wípé, "Ó lè ṣe bẹ́ẹ̀."

Nígbà tí ó sì wa ra ẹ̀yìn mi lọ́wọ́, ó sọ wípé "ti ìjọ-àdámọ̀ wo ni o jẹ́?"

Mo sì wá sọ wípé, "Mo jẹ́ ti ìjọ ti o dàgbà jùlọ."

O sì wa wípé, "Ìjọ wo ni èyí?"

Mo sọ wípé, "O jẹ́ èyí tí ó ti wa ṣáájú kí ayé kó tó wà".

Ó sì wa sọ wípé "Kínni n la?... N kò gbàgbọ́ pé mo mọ èyí ni…" O wípé, "Mo jẹ́ ti ìjọ kan bayi bayi. Ṣe òhun ni?"

Mo sọ pé, "Rárá ìyá-àfin, ìjọ rẹ̀ kò ti ju igba ọdún péré lọ. Ṣùgbọ́n àgbá-ìjọ yìí bẹ̀rẹ̀ ní ìgbà tí àwọn ìrawọ òwúrọ̀ n kọrin pọ̀, tí àwọn ọmọ Ọlọ́run sì n pariwo fún ayọ̀, nígbàtí wọ́n rí bíbọ̀ Olùgbàlà kan láti gba aráyé là".

30 Ó sì wa dáwọ́ dúró láti máa ra ẹ̀yìn mi, mo sì bẹ̀rẹ̀ díẹ̀ ki obìnrin yi le rí ẹyin mi ra, (láti ìlú tí ó súnmọ́ Corydon ni ó sì ti wá), a sì wá ń sọ̀rọ̀, nígbànáá ni ó wípé, "Alàgbà, mo ti máa n gbàgbọ́ wípé tí Ọlọ́run bá sì n jẹ́ Ọlọ́run, ó jẹ́ Ọlọ́run kan náà lónìí gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ ní ìgbà àtijọ́". Ó wípé, "Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ìjọ mi kọ èyí sílẹ̀ pátápátá, ṣùgbọ́n mo sì gbàgbọ́ wípé òtítọ́ ni".

Mo sì wípé, "O ko jìnnà sí ìjọba Ọlọ́run, ọ̀dọ́mọbìnrin".

O sọ wípé, "Tí ó bá jẹ́ olùwòsàn tẹ́lẹ̀, ǹ jẹ́ kìí tún ṣe olùwòsàn síbẹ̀ bí?"

Mo sọ wípé "Bẹ́ẹ̀ ni o ri ni dájúdájú, arábìnrin mi."

31 Ṣùgbọ́n eniyan fẹ́ máa ṣe àkóso eniyan, eniyan sì fẹ́ kí eniyan má ṣe àkóso òhun. Kò fẹ́ kí Ọlọ́run máa ṣe àkóso ohun tí wọ́n fẹ́.

Ọmọ Kiiṣi yi (saulu) jẹ idahun si ohun ti wọn fẹ. Akin ọkùnrin tí ó síngbọnlẹ̀ ti…. Ó le darí wọn lọ sí àwọn ogun wọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Síbẹ̀, kìí ṣe ọ̀nà tí Ọlọ́run máa ń fi ṣe àwọn nǹkan. Ọlọ́run fẹ kí àgbà wòlii òdodo Rẹ̀ si máa darí wọn kí ó sì máa sọ̀rọ̀ Rẹ̀ fún wọn.

32 Nisisiyi, nínú igba ìjọ èyí tí a ń gbé inú rẹ̀, mo rò, mó si gba èyí gbọ́ pẹ̀lú gbogbo ọkàn mi, wípé a ti lòdì sí ohun tí Ọlọ́run yàn wá láti ṣe. Ọ̀rọ̀ ìkẹyìn ti Olùgbàlà wa wà nínú ìwé Máàkù orí ìkẹrìndínlógún, ó wípé; "Ẹ lọ sí gbogbo ayé, kí ẹ sì máa wàásù ìhìnrere sí gbogbo ẹ̀dá. Ẹnití ó bá gbàgbọ́ tí a sì tẹ bọ omi ni a o gbàlà; ẹnití kò bá gbàgbọ́ yóò jẹ̀bi. Àmì wọ̀nyí ni yóò sì máa bá àwọn tí ó gbàgbọ́ lọ. Ní orúkọ mi ni wọ́n yóò máa lé àwọn ẹ̀mí èṣù jáde; wọn yóò sì máa fi èdè titun sọ̀rọ̀; tí wọ́n bá sì gbé ejò tàbí mú ohun olóró kan, kí yóò pa wọ́n lára; tí wọ́n bá sì gbé ọwọ́ lé àwọn olókùnrùn ara wọn yóò dá."

33 Kò sí ọkùnrin kan, kò sí ọmọ Kíṣìì kan, tàbí ẹnikẹ́ni tí ó lè mú èyí ṣẹ láì si ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́. Ṣùgbọ́n a ti dá àwọn ilé kalẹ̀, a tí da àwọn ilé-ẹ̀kọ́ Bíbélì kalẹ̀, àti àkójọpọ̀ àwọn ìjọ fún ìtẹ̀lọ́rùn kí a fi le dàbí ayé ṣe rí.

Nisisiyi, Ẹ̀mí Mímọ́ ló ti máa ń jẹ́ olórí ní orílẹ̀-èdè yìí. Orílẹ̀-èdè yìí ni a ti ń darí rẹ̀ tẹ́lẹ̀, nígbàtí…. Nígbàtí wọ́n kọ Ìkéde Òmìnira tí wọ́n sì gbé àga ìjókòó kan kalẹ̀ ni òfifo. Èmi kò ní iyèméjì kankan ní ọkàn mi wípé ọmọ Ọlọ́run náà jókó níbi tábìlì náà nígbàtí a fi orílẹ̀-èdè yi lọlẹ̀ ni orí àwọn ìpìlẹ̀ òmìnira ẹ̀sìn, àti òmìnira fún gbogbo àwọn eniyan, àti lórí ìpìlẹ̀ ọ̀rọ̀ àìnìpẹ̀kun tí Ọlọ́run. Ṣùgbọ́n a ti fi òṣèlú ba èyí jẹ́. A ti dìbò fún àwọn ọkùnrin kan lábẹ́ kátà-kárà àti awọn ìlérí èké, de ibi tí orílẹ̀-èdè wa àti òṣèlú wa àti ìjọba tiwa-n-tiwa ti di aláìmọ́ tìtí o sì fi dàpọ̀ mọ́ iṣẹ́-ẹ̀kọ́ kọmunisimu (communism) àti àwọn ìṣe mìíràn pẹ̀lú.

34 Àti ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà tí a bá sì pè fún àkókò àdúrà, nígbàtí àwọn àjùmọ̀ṣe orílẹ̀-èdè bá si pàdé pọ̀ níbẹ̀, tàbí láti jíròrò. Àti ni àìpẹ́ yìí, kò ti lẹ sí ìgbà kan tí wọ́n pé fún àdúrà! Báwo ni a ó ti ṣe le parí ìjà láìsí àdúrà? Báwo ni a ṣe lè ṣe ohunkóhun nínú ayé láìsí ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́?

Ṣùgbọ́n mo fẹ́ sọ èyí pẹ̀lú ìfẹ́ àti tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ sí orílẹ̀-èdè wa, àti sí àsìá rẹ, àti fún òmìnira tí ó dúró fún; a ti kọ olórí wa, Ẹmi Mimọ, àti nípasẹ̀ ìdíbàjẹ́ òṣèlú, a sì ti mú àwọn eniyan ọlọ́kan eeri wọlé. Tí ẹ kò bá si kíyèsára, wọn yóò ṣe ọ̀kan nínú àwọn àṣìṣe tí ó burú jai tí wọ́n ti ṣe rí nisisiyi. Nítorípé àwọn eniyan ń fẹ́ kí eniyan máa darí wọn ni.

35 Ohun tí a nílò ní ilé-ìjọba orílẹ̀-èdè parapọ̀ (U.S.A.) yìí gẹ́gẹ́ bi Ààrẹ, ohun tí a nílò ni ìgbìmọ̀ aṣojú-ṣòfin, ohun tí a nílò nínú gbọngan ìdájọ́ ní àwọn ọkùnrin tí wọ́n ti fi ayé wọn jì fún Ọlọ́run, tí wọ́n sì kún fún Ẹ̀mí Mímọ́, tí a sì ń darí wọn pẹ̀lú ìtọ́ni láti ọ̀run wa. Ṣùgbọ́n dípò èyí, a yan àwọn eniyan ọlọ́gbọ́n-orí, àwọn ẹnití wọ́n ni àfarawé ìwà bíi Ọlọ́run ṣùgbọ́n tí wọ́n ṣẹ́ agbára Ọlọ́run, àwọn eniyan tí wọ́n jẹ kèfèrí àti ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà wọn tún burú jù bẹ́ẹ̀ lọ- àti mu wọn wa si ìpele òṣèlú orílẹ̀-èdè wa.

Kì í ṣe èyí nìkan ṣugbọ́n nínú àwọn ìjọ wa. Àwọn ìjọ wa ti dí bàjẹ́ lorí wípé, nígbàtí a ba n yan àwọn olùsọ́-àgùntàn ti yóò ma darí wa, a ti lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ Bíbélì láti yan àwọn ọkùnrin tí wọ́n jẹ́ àwọn òmìrán ọlọ́gbọ́n-orí, àwọn ọkùnrin tí wọ́n mọ ìwé dáadáa, àwọn ọkùnrin tí wọn dáńtọ́ nínú ẹ̀kọ́, ti wọn sì jẹ́ àwọn dọlápọ̀ laarin àwùjọ eniyan, tí wọn jẹ́ àwọn ẹni ńlá laarin àwọn aládúgbò - ti n ko sì ni ohunkóhun láti sọ tako wọn. Àwọn ọkùnrin tí wọ́n mọ̀ọ rin dáadáa nínú ọna wọn, tí wọ́n a sì máa kíyèsára ní gbogbo ọnà ayé wọn, àti bi wọn ti ṣe n hùwà laarin àwọn eniyan yókù, àwọn ọkùnrin ńlá nínú iṣẹ́ ti wọn yàn láàyò, èyí ti n ko sọ̀rọ̀ ibi nípa rẹ̀ - kí Ọlọ́run ma jẹ́ kí ọkàn mi burú jàì tó bẹ́ẹ̀. Ṣùgbọ́n síbẹ̀, èyí kọ́ ni Ọlọ́run yan fún wa! Ìdari Ẹ̀mí Mímọ́ ni, Krístì nínú ọkàn eniyan.

36 Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọlọ́gbọ́n-orí ọkùnrin tí wọn n dúró lẹ́yìn pẹpẹ wa ni o ṣẹ́ wíwà laaye Ẹ̀mí Mímọ́. Ọ̀pọ̀lọ̀ọ̀pọ̀ wọn ni o ṣẹ́ wíwà ìwòsàn láti ọ̀run wá àti agbára Ẹmí.

37 Mo ka àkọsílẹ̀ kan (Mo gbàgbọ́ wípé ni àná ni), àwọn àkọsílẹ̀ pélébé láti inú ìwé ìròyìn Jack Coe, Olóògbé Jack Coe, ọkàn nínú àwọn tí mo jere ọkàn rẹ̀ fún Jésù Olúwa, ẹni tí í ṣe ọkùnrin alágbára ni ọjọ́ ayé rẹ̀, tí a sì dojú ìbéèrè kọ ni ìlú Florida, nítorípé ó sọ fún ọmọdé kan tí ó yarọ pé kí ó yọ ọ̀pá tí wọ́n fi mú ẹsẹ̀ rẹ ró kúrò kí ó sì rín kọjá lórí ìtàgé náà ní pípé, o si ṣubú nígbàtí ó dé ọ̀dọ̀ ìyá rẹ̀ - ọta Krístì ni o si ti gbé ète kalẹ̀.

Ọ̀dọ́mọbìnrin yìí àti ọkọ rẹ̀ pe arákùnrin wa akọni eniyan lẹ́jọ́ ní ilé ẹjọ́. Nígbàtí ó sì yẹ kí gbogbo ìjọ dúró tí Arákùnrin Jack, nígbàtí gbogbo ọmọ-ìjọ ti n pe orúkọ Jésù Krístì kunlẹ ni orúnkún wọn nínú àdúrà, ṣùgbọ́n dípò èyí, àkọ́lé gbogbo ìwé ìròyìn, ọkan nínú àwọn ìjọ-àdámọ̀ ńlá kan sọ wípé wọn sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn kèfèrí láti da Arákùnrin Jack Coe lẹ́bi kí wọ́n sì fi sínú túbú. Ǹ jẹ́ ẹ le ró wípé ìjọ ti wọn fi orúkọ Krístì pe ara wọn, yóò sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn kèfèrí láti da eniyan Ọlọ́run lẹ́bi ẹnití ó ń gbìyàjú pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ̀ láti dúró fún Bíbélì? Ṣùgbọ́n wọn ṣe e.

38 Arákùnrin Gordon Lindsay si wa lati gba arakunrin wa silẹ, nígbàtí alàìgbàgbọ́ adájọ́ náà si sọ wí pé, "Ẹlẹ́tàn ni ọkùnrin yìí, nítorí pé ó yọ àwọn igi tí ó gbé ẹsẹ̀ ọmọ náà ro kúrò ó sì wa ran lọ ni orí ìtàgé, tí ó sì wipé ó ti di ẹni ìwòsàn; ó sì parọ tí ó sì tún ṣe ohun tí o tako àwọn àṣẹ dókítà. Nítorínáà, a fi ẹ̀sùn ìtannijẹ́ kan an."

Ọ̀gbẹ́ni Coe si dìde dúró, ó wípé, "Alàgbà, mo tako ọ̀rọ̀ yii. Ọlọ́run wo ọmọ náà sàn."

Adájọ náà sí wípé, "Èmi yóò béèrè nínú ilé-ẹjọ́ yìí bi ọ̀rọ̀ náà bá jẹ́ òtítọ́ wípé Ọlọ́run le wo ọmọkùnrin náà san ni ẹgbẹ́ kan lórí ìtàgé, kí ó sì wa jẹ́ kí o ṣe àìsàn ni ẹgbẹ́ mìíràn. Tí a bá ri ẹni fi ìdí ọ̀rọ̀ náà múlẹ̀ pẹ̀lú ìwé mímọ́, nígbànáà ni n o tó gbà wípé Ọ̀gbẹ́ni Coe ni ẹ̀tọ́ sí ọ̀rọ̀ rẹ̀ tí ó sọ.

Oníwààsù (òjíṣẹ́) kan si gbé ọwọ́ rẹ̀ sókè, ó sọ wípé "Ọlọ́lájùlọ, alàgbà, ǹ jẹ́ mo lè fèsì sí ọ̀rọ̀ yìí?"

Adájọ́ náà si sọ wípé, "máa sọ ọ̀rọ̀ rẹ̀ n so."

39 Ojíṣẹ́ náà si dìde dúró ni ẹsẹ̀ rẹ̀, ó wípé, "Ni alẹ́ ọjọ́ kan nígbàtí ìgbì òkun ńru, nígbàtí ọkọ̀ kékeré náà fẹ́ rì sí ìsàlẹ̀, gbogbo ìrètí làti lá kò sì mọ. Wọ́n ri Jésù, ọmọ Ọlọ́run, tí ó ń rin lórí omi. Ọ̀kan nínú àwọn àpóstélì, ẹnití orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Peterù, sọ wípé; "tí o bá ṣe pé ìwọ ni Olúwa, pàṣẹ fún mi kí ń máa bọ̀ lórí omi", ó sì wípé… Olúwa sọ fún Peteru wípé, 'máa bọ̀ wá, ó sì jáde láti inú ọkọ̀ ojú-omi, alàgbà, tí ó sì ńrìn lórí omi gẹ́gẹ́ bí Jesu

ti ṣe ń rìn. Ṣùgbọ́n nígbà tí ẹrù bàá, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní rìì kí ó tó dé ọdọ̀ Jesu.

Adájọ́ náà sì sọ wípé, 'a tu ẹjọ́ naa ká'.

40 A nílò ìdarí Ẹmí Mímọ́-kìí ṣe àwọn ọlọ́gbọ́n-orí eniyan.

Saulu, ọmọ Kiiṣí ni wọ́n fi jẹ Balógun lórí àwọn eniyan, ó sì yan àwọn ẹgbàá ọkùnrin tí Jònátánì sì lọ mú àwọn ẹgbẹ̀rún, Jonátànì sì sọ̀kalẹ̀ lọ sí ààrín ẹgbẹ́ ọtun, ó sì pa àwọn ará Amórì-tàbí àwọn Amoni. Nígbà tí ó sì ti pa wọ́n tán, Saulu wá bẹ̀rẹ̀ sí ní fún ipe wípé, 'Ẹ kó há rí ohun tí Saulu ti ṣe'. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní gbéraga.

Kété tí eniyan bá sì ti bẹ̀rẹ̀ sí ní í di ọ̀mọ̀wé nípa Ọlọ́run, tàbí tí ó ní àwọn àpèlé kékeré kan lẹ́yìn orúkọ rẹ, ó ti wá di ẹniti ó ti mọ̀ ọ́ tán'. Àwọn ọkùnrin Ọlọ́run jẹ́ àwọn onírẹ̀lẹ́. Àwọn eniyan Ọlọ́run jẹ́ àwọn onírẹ̀lẹ̀.

Tí o ba rí ẹnikan tí ó sọ wípé àwọn ti gba Ẹmí Mímọ́ tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí ní yapa, tí ó dàbí àwọn tí kò níí ìgbàgbọ́, tí wọn sì bẹ̀rẹ̀ sí ní yapa, tí ó dàbí àwọn tí kò ní ìgbàgbọ́, tí wọn sì bẹ̀rẹ̀ sí níí lọ láti jẹ́ ohun tí wọ́n kò jẹ́, ẹ rántí wípé nwọ́n kò ti gba Jesu Olúwa.

41 Nígbà náà ni a sì wá rí pé ọtá wọlé wá, yóò sì wá sí ààrín ẹgbẹ́ àwọn eniyan Ọlọ́run tí yóò sì wá yọ ojú ọtún gbogbo àwọn eniyan kúrò. Ohun tí ọ̀tá ń máa gbìyànjú láti ṣe nìyìí, ohun ni láti yọ ojú méjèèjì jáde ti ó bá ṣeéṣe fún un kí àwọn eniyan lè má rí ohun tí wọ́n ń ṣe mọ́. Ohun tí Sàtánì ń gbìyànjú láti ṣe lóní nìyí fún gbogbo Kristẹni: láti yọ ojú ẹmí rẹ̀ kúrò, kí ó lè tẹ̀lé ọgbọ́n-orí nìkan tí kìí sì ṣe ọgbọ́n Ẹ̀mí Mímọ́ láti darí rẹ̀.

Nígbà tí wọ́n sì ti ṣe èyí, nígbà tí ìjàkulẹ̀ ńlá dé Saulu sì gé Maalú ńlá ṣíméjì, ó sì fi ránṣẹ́ sí àwọn eniyan. Yóò sì wù mí pé kí ẹ kíyèsí ni ibiyí, nígbàtí Saulu fi àwọn ẹran tí ó gé sí wẹ́wẹ́ wọ̀nyí ránṣẹ́ sí gbogbo Israeli tí ó sì wípé; "Jẹ́ kí gbogbo àwọn tí kì yóò tẹ̀lé Samueli àti Saulu, jẹ kí ẹni bẹ́ẹ̀, Maalu yìí… dàbí rẹ̀". Ǹjẹ́ ìwọ lè rí bí ó ti ṣe gbìyànjú láti fi eniyan Ọlọ́run dípo ara rẹ bí? Bí ó ti ṣe tako ìwà Kristẹni tó. Ẹ̀rù tí àwọn eniyan ni nítorí tí Samueli. Ṣùgbọ́n Saulu mú kí gbogbo àwọn eniyan tẹ̀lé òun nítoripé àwọn eniyan bẹ̀rù Sámueli. "Jẹ́ kí wọ́n tẹ̀lé Samueli àti Saulu lẹ́yìn".

42 Ní ọpọ̀lọpọ̀ ìgbà lóní ni a ti gbọ́ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀: "Awa ni ijọ nla," "Awa ni ijọ ti Kristi," "Awa ni ijọ Ọlọrun," "Awa ni ijọ tọ̀hún". Ó jẹ́ kí àwọn eniyan bẹ̀rù, tí wọn sì ronú wípé ibití Ọlọ́run ti ń ṣiṣẹ́ gan ni yẹn. Wọ́n kò sì fẹ́ idarí Ẹmi Mímọ́; wọ́n yóò kúkú tẹ̀lé irú àwọn eniyan bẹ́ẹ̀, nítorí pé, wọn fẹ́ láti máa gbé ìgbé ayé ti ara wọn. wọ́n fẹ́ láti gba ohun tí wọ́n fẹ gbọ́.

Ǹjẹ́ ìwọ há rí wípé Ẹmi Mímọ́ ni Onídájọ́ wa? Ọlọ́run kò fún wa ní Pope kan, tàbí Bíṣọ́bù kan, tàbí ẹnikẹ́ni láti jẹ́ onídájọ́ kan. Ẹ̀mí Mímọ́ Ọlọ́run fún ara Rẹ̀ ni irí Ẹ̀mí Mímọ́, ni onídájọ wa àti amọnà wa.

43 Nísisiyi, kinni ó dé tí ó fi rí bẹ́ẹ̀?

Ẹ jọ̀wọ́ kí ẹ fi àyè gbà ọ̀rọ̀ líle àti alàyé líle jùlọ yìì. Ǹ kò fẹ́ láti fi èyí pẹ̀gàn; mo sọ èyí láti inú ìfẹ́. Ṣùgbọ́n Ẹ̀mí Mímọ́ sọ wípé ó kunà fún àwọn obìnrin láti gé irun wọn, ó sì kùnà fún àwọn obìnrin wa láti wọ aṣọ tí ó kéré àti àwọn ṣòkòtò àti láti kun ètè wọn àti ojú wọn pẹ̀lú ọ̀dà. Ẹmí Mímọ́ sọ wípé ó kùnà, ṣùgbọ́n a fẹ́ kí àwọn eniyan sọ fún wa wípé o dara.

Níwọ̀n ìgbà tí a bá tẹ̀lé, "èmi àti Samueli", nwọ́n fẹ́ lati gbé bí ó ṣe wù wọ́n fún ọjọ́ mẹ́fà, kí wọn sì lọ sí ilé ìjọ́sìn ní òwúrọ̀ ọjọ́ Àìkú; tí akẹ́kọ́-gboyè tí ó ní ọgbọ́n-orí pẹ̀lú ọpọ̀lọpọ̀ òye-ẹ̀kọ́, ìmọ̀ lè báwọn sọ̀rọ̀ ìwàásù kékeré kan tí yóò… àwàdà díẹ̀ tí yóò mú etí wọn gbọ̀n tí yóò sì jẹ́ ẹ̀fẹ̀ bíi òṣèré orí ìtàgé tàbí tí amohun-máwòrán (tẹlifíṣàn), tí yóò sì gba àdúrà ṣókí fún wọn, tí yóò sì rán wọ́n padà lọ sí ilé wọn pẹ̀lú ìtẹ́lọ́rùn tí ara ẹni wípé àwọn tí ṣe ẹsìn tí wọn.

Èyí kìí ṣe ìfẹ́ Ẹ̀mí Mímọ́. Ẹ̀mí Mímọ́ fẹ́ kí ó gbé ìgbé ayé ìwà bí Ọlọ́run nígbogbo àwọn ọjọ́ tí ó wà nínú ọ̀sẹ̀ àti ní gbogbo alẹ́, tí ó sì ti ya ara rẹ̀ nípa kúrò nínú ohun ayé. ṣùgbọ́n ìjọ kò fẹ́ èyí, wọ́n fẹ́ ẹnití ó lè ṣe ìtúmọ̀ Bíbélì ní ọ̀nà tí wọn fẹ́ gbọ́. Wọn kò ní tẹ etí láti gbọ́ ohun Ẹ̀mí Mímọ́ tí ó ń sọ̀rọ̀ nípasẹ̀ Bibélì.

44 Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn fẹ́ sọ wípé, "àwọn ọjọ́ iṣẹ́-ìyanu tí kọ́já". Ohun tí etí àwọn ènìyan ńgbọ́ sì nìyí. Wọ́n fẹ́ sọ wí pé, "ko sí ìtẹ̀bọmi Ẹ̀mí Mímọ́." Àwọn eniyan kò fẹ́ hùwà tí ó yàtọ̀ sí àwọn eniyan ayé. wọ́n kò fẹ́ lọ sí ojú pópó pẹ̀lú ojú tí wọn ti fọ̀ nù, àti àwọn ọkùnrin pẹ̀lú ojú mímọ́ tí kò sí tábà ni ẹnu wọn, àti kòkò tábà pẹ̀lú tábà nínú rẹ̀, àti àwọn ohun tí àwọn eniyan ń ṣe, àwọn obìnrin sì fẹ́ gé irun wọn kúrú tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ pẹ̀lú ṣòkòtò kékeré àti àwọn aṣọ kékeré lọ́rùn wọn, tí wọn sì ń fi ìrí ara wọn hàn àti ohun tí wọ́n fẹ́. Wọ́n fẹ́ ẹnití yóò sọ fún wọn wípé ó dára bẹ́ẹ̀.

45 Nígbà náà ní alẹ́ ọjọ́ kan ni ọkùnrin kan wá láti sọ fún mi wípé nítorí tí mo ti wàásù tako ohun báyí báyí wípé ijọ-adámọ ńla kan, ó tó bí márùn-ún wọn, wọ́n sọ wípé, "A kò ní bá Arákùnrin Branham ṣe pọ̀ mọ́, a ó kọ ọ́ sílẹ̀. Nínú kí ó gba àwọn ohùn tí a gbà sílẹ̀ nínú ẹrọ-ìgbóhùn sílẹ̀ padà kí o má jáde mọ́ kí ó sì tọrọ àforíjì fún, tabi kí a kọọ sílẹ̀".

Mo wá sọ wípé; Èmi yóò dúró pẹ̀lú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run bí ẹ tilẹ̀ gba gbogbo ohun tí ó wà nínú ayé mi. N o dúró pẹ̀lú Ọ̀rọ̀ àti…

Wọ́n sì wípé, "ṣe ó kò ní gba àwọn ohùn ìwàásù báyíbáyìí padà".

Mo wípé, "N kò ti wàásù ohunkóhun nínú ayé mi tí ojú rẹ timí rí. Ǹ kò ní gba àwọn ohùn ìwáásù tàbí ẹrọ ìgbohùnsílẹ̀ padà. N o dúró pẹ̀lú ohun tí Ẹmí Mímọ́ wí. Èyí ni n o máa gbé fún tí n o sì kù fún", Ǹ kò gbìyànjú láti sọ èyí nítorí ara mi nísisiyi, ṣùgbọ́n mo kan ńgbìyànjú láti fún yín ní apẹrẹ-àlàyé ohun tí ó ń ṣẹle kí ẹ sì lóyè. Àwọn eniyan ni wọ́n fẹ́ kí ọkùnrin máa darí wọn.

46 Wọ́n kò fẹ́ Samuelì, kí wọn sì tó fi òróró yan Samuel gẹ́gẹ́ bí ọba-tàbí Saulu lọ́ba, mo tọọrọ àforíjì, Samueli tọ wọn wá lẹẹkansí. Mo sì fẹ́ láti sọ ọ́ ní ọ̀nà tí yóò gbà sọọ́ lóní. Ẹ lè kàá.

Ó sọ wípé, "kinni ohun tó kunà wípé Ọlọ́run jẹ́ ọba yín?"

"Ṣùgbọ́n ṣáá, àwa kò rí Ọlọ́run",

"Emi gan-an ni aṣojú Rẹ̀". Samuel sọ wípé, Ǹjẹ́ mo ti sọ ohun tí ó kùnà fún yín rí bíi? N jẹ́ mo há ti sọ ohunkóhun tẹ́lẹ̀ rí tí kó wa sí ìmúṣẹ gẹ́gẹ́bí mo ti sọ wípé yóò rí bí? Njẹ́ n kò há ti sọ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run fún yín bí? N o béèrè èyí lọ́wọ́ yín "Njẹ́ mo ti tọ̀ yín wá láti bẹ̀bẹ̀ fún owó bí? Ǹjẹ́ mo ti gba ohunkóhun lọ́wọ́ yín bí? Njẹ́ mo há ti sọ ohun kan fún yín bíkòṣe "Báyí ni Olúwa wí?" tí Ọlọ́run sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ nígbà gbogbo wípé òtítọ́ ni, O sì ran ara ńlá àti òjò". Ẹyin mọ wipe ìwé Mímọ́ fi ìdí Samuelì múlẹ̀ gẹgẹ́bí agbẹnusọ fún Ọlọ́run.

Àti gẹ́gẹ́ bí Samuel ti dúró fún Ẹ̀mí Mímọ́ lọ́nà pípe lónìí yìí, Ẹ̀mí Mímọ́ ni agbẹnusọ fun Ọlọ́run tí ó ń sọ ohun tí Bibélì sọ. Ní bẹ́ẹ̀, tí ó sì gba ohun tí Bíbélì sọ gbọ́ tí kò sì ní yẹ̀ kúrò níbẹ̀. Ṣùgbọ́n wọn ń fẹ́ ẹnití ó lè sọ ohun tí ó yàtọ̀ fún wọn.

47 Àwọn ènìyan kò sì lè sọ wípé àsọtẹ́lẹ̀ Samúẹ̀lì kò jẹ́ pípé. Wọn dáhùn wípé, "Samueli, gbogbo ohun tí ó ti sọ ní orúkọ Olúwa, Olúwa ti mú wá sí ìmúṣẹ gẹgẹ́ bí ó ti ṣe sọ wọn, kò sí àbùkù kan, ó kò tii tọ wá wá láti bẹ̀bẹ̀ fún owó. O ti kin ara rẹ̀ lẹ́yìn, o kò tilẹ̀ béèrè pé kí a ṣe ohun ńlá kan fún ọ. O ti gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run rẹ̀, Ó sì ti gba ọ́ nínú ohun gbogbo. Òtítọ́ sì ni àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀, ohun gbogbo tí ó sọ ní orúkọ Olúwa ti ṣẹ gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wí, ṣùgbọ́n sibẹ, a sì ń fẹ́ ọba kan!"

48 Ǹ jẹ́ ẹ lè rí ìwà-òdì bíi? Ǹjẹ́ ẹ lè rí àrékérekè ti eṣu bí ó ti lè ṣiṣẹ́ lórí eniyan bíi? Dípò kí ó fi ara rẹ jì, ọkùnrin tàbí obìnrin, fún Ẹ̀mi Mímọ́ kí ó sì tẹ ètí sílẹ̀ láti gbọ ohùn tí "Báyìí ni Olúwa wí" jẹ́ fún ìgbé-ayé mímọ́, ìwà tí kò lábàwọ́n, fún ìgbé-ayé tí ó yàtọ̀, eniyan ọ̀tọ̀, orílẹ̀-èdè mímọ́, àwọn eniyan tí ìwà wọn ṣe àjèjì, ṣùgbọ́n wọn fẹ́ láti bá ayé dọ́gba, àti láti hùwà bí ayé, kí wọn sì lọ sí àwọn ilé-ijọsin kan tí wọ́n sì máa ń sọ wí pé, "ó dára bẹ́ẹ̀. Ẹ máa tẹ̀síwájú bí ẹ ti ṣe nhùwà".

Ǹjẹ́ ẹ lè rí ohun tí ó jẹ́? Wọn sọ wípé, "kò sí ohun tí ó ń jẹ ìwòsàn, kódà, ìtẹ̀bọmi ti Ẹ̀mí Mímo jẹ́ ìlànà kan nínú ijọ ni". Ní ọ̀rọ̀ míràn, nígbà náà Ọlọ́run mú àwọn eniyan kúrò, ó sì mú Ẹ̀mí Mímọ́ kúrò nínú ìjọ, àti wípé o fi àyè gbà ìjọ-àdámọ̀ láti kọ́ ọ. Láyéláyé, kò sí ohun tí ó ń jẹ́ bẹ́ẹ̀. Ẹ̀mí Mímọ́ náà, Ọ̀rọ̀ òtítọ́ náà wá láti máa darí rẹ̀ títí Jesu yóò fi dé. Ṣùgbọ́n bí ó ti ṣe lọ ni yẹn.

49 Saulu gba ìṣàkóso, ó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èrò tí ó ń tẹ̀lé lẹ́yìn. Kódà, ó ní àwọn ìhámọ́ra ti o dára, ó ní àwọn akọrin, ó ní àwọn aṣà, ó ní àwọn ọ̀kọ̀. Kódà, o ń dán ju gbogbo àwọn orílẹ̀-èdè yóòkù lọ. Ó sì mú wọn wá sinú ìjọba-tiwantiwa tí ó tayọ èyítí ẹnikẹni tii gbọ nípa rẹ̀ lọ

Èyí sí ni ohun tí àwọn ijọ-àdámọ̀ wa àti gbogbo àwọn ijọ ti ṣe lóní. Awa la ní ilé-ìjọ́sìn tí ó to bí jù ní àgbáyé. A ní ètò-ẹ̀kọ́ tí ó ga jù tí eniyan lè mú wa. Gẹ́gẹ́ bí àwọn Ọkùnrin tí Saulu tí kọ bí wọ́n ṣe lè lo ọ̀kọ̀ wọn ní ọ̀nà tí àwọn orílẹ̀-èdè fí bẹ̀rù wọn. Wọn jẹ́ àwọn eniyan tí wọ́n ti kọ ní gbogbo rẹ̀.

Ṣùgbọ́n lọ́jọ́ kan, ni olùpèníjà kan jáde wá, ó sì kó ìdágìrì bá gbogbo àwọn ọmọ-ogun Israeli tó bẹ́ẹ̀ tí wọn sì ń gbọ́n nínú bàtà wọn. Goliatì pè wọ́n níjà: Ti Ọlọ́run yín bá jẹ ohun tí ẹ sọ pé ó jẹ́, ẹyin ni ẹ ní ẹ̀kọ́ tí ó dára jùlọ… ó sì pe wọ́n níjà. Wọn kò sì mọ ohun tí wọ́n kìí bá ṣe. Àwọn ìhámọ́ra wọn tí ó dára tí ó sì ńdán kò lè ṣe iṣẹ́. Àwọn ọ̀kọ̀ wọn kò lè ṣe iṣẹ́. Ohun kan ńṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ tí wọn kò ti gbọ́ irú rẹ̀ rí.

50 Pẹ̀lú gbogbo ọ̀wọ̀, àti ìtẹ́ríba-ìwà bí Ọlọ́run, àti ọlá àti iyì, àti ìfẹ́, àti ìdàpọ̀ Kristẹni, mo sọ èyí: Mo ka ní ọjọ́ kan nínú ìwé ìròyìn Afrika kan ní ibi ti ọmọ Kìiṣí wà, Olùpèníjà ihinrere wa, nígbà tí ọmọlẹ́yìn Mohamedi tí pe é níjà (Billy Graham), wípé: Ti Ọlọ́run rẹ bá sì jẹ́ Ọlọ́run, jẹ́ kí ó wo aláìsàn san gẹ́gẹ́ bi ó ti ṣe wi!" Ọmọ Kìiṣí náà, pẹ̀lú gbogbo àwọn ọmọ-ogun tí o kù, wọn dákẹ́jẹ́ wọn sì kúrò ní orílẹ̀-èdè náà pẹ̀lú ìjákulẹ̀. Ó jẹ́ ìtìjú. Ọlọ́run wa Ọlọ́run ni!

A ní àwọn ijọ wa, a ní ijihinrere ti wa tó dára, a ní àwọn akọrin tí wa tí a ń san owó iṣẹ́ fún, a ní ẹgbẹ́ akọrin tí ó dara jùlọ, pẹ̀lú ìloro tí ó ga jù ní orílẹ̀-èdè. A ní àwọn ọkùnrin tí ó dara julọ, pẹlu ọpọlọpọ̀ owó, a ní àwọn ọlọ́gbọ́n-orí, a ní ẹkọ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tó múná dóko. A lè wàásù rẹ̀, a lè sọ ọ́, a lè jihinrere ki a sì mú àwọn

eniyan wọlé wá, kí a sì jèèrè ọkẹ àìmoye ọkan sínú ijọ. Àwọn ẹgbẹ́ akọrin ti a ń ṣàn owó iṣẹ́ fún, ijihìnrere tí a ń fi ọgbọ́n orí ṣe kò lè mọ bi a ti ṣe lè bá irú ìpènijà bẹ́ẹ̀ pade. Wọn kò mọ ohun kan nípa rẹ. Wọn ko mọ ohun kan nípa agbara ìwosàn Rẹ̀, nípa ìtẹbọmi Ẹmí Mímọ́, nípa agbára tí ó lè mú kí eniyan ti ó ń ku lọ pẹ̀lú arùn jejẹrẹ di ominira. Wọn kò mọ ohun kan nípa rẹ̀. A kò tíì kọ wọ́n lọ́nà bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ bí Saulu àti àwọn àtọwọ́dá ẹgbẹ́ rẹ̀.

51 Ṣùgbọ́n jẹ́ kí ń sọ èyí fún àwọn eniyan Ọlọ́run àti ẹ̀yin ọmọ wípé, kí ẹ lè mọ pé Ọlọ́run kì yóò fi yín sílẹ̀ láìsí ẹlẹ́rí kan. Laimọ fún Saulu - Saulu kò mọ ohun kan nípa rẹ̀- ṣùgbọ́n Ọlọ́run ni Dafidi kékeré kan lẹ́yìn òkè ní ibikan tí kìí ṣe pé ó ń fi koríko ẹ̀kọ́-ìjọ bọ́ àwọn àgùntàn. Ó ń darí wọn lọ sí ibití omi ti dákẹ́ rọ́rọ́ àti nínú pápá oko tútù! Ó ń ṣe àmojútó àwọn àgùntàn bàbá rẹ, tí ẹnikan bá sì sáré wọlé wá, ọta kan, láti gbé ọkan nínú àgùntàn bàbá rẹ̀, ó mọ agbára Ọlọ́run láti gba àwọn àgùntàn náà sílẹ̀!

Ọlọ́run sì tún ní Dafidi kan ní ibikan tí ó sì mọ̀ bí a ti gba ọ̀kan nínú àwọn àgùntàn Ọlọ́run là pẹ̀lú agbára Ọlọ́run. Ó sì tún mọ nípa gbogbo rẹ, ó ti gbẹ́kẹ̀lé…kò mọ ohunkóhun nípa ìhámọ́ra Saulu, bẹ́ẹ̀ sì ni kò fẹ́ ohunkóhun pẹ̀lú rẹ̀. Kò fẹ́ ohun kan nínú àwọn ijọ-adàmọ̀ wọn; kò fẹ́ ìhámọra àtijọ́ nnì ní ara rẹ̀, ó sọ wípé; “N kò mọ ohunkóhun nípa rẹ̀! Ṣùgbọ́n jẹ́ kí ń lọ nípa agbára tí mo mọ̀”.

52 Ó ti ń bọ́ àwọn àgùntàn bàbá rẹ ó ti ń tọ́jú àwọn agbo pápá oko náà, ó ti ń fún wọn ní oúj̣ẹ tí ó yẹ, wọ́n sì ti ń gbé ti wọn sí ń ṣe rere. “eniyan kì yóò wà láàyè nípa àkàrà nìkan, ṣùgbọ́n nípa gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó ń ti ẹnu Ọlọ́run jáde ni eniyan fi lee wà láàyè”. Olùṣọ́-àgùntàn rere ló ńbọ́ wọn - “Jesu Kristi, ọkàn ni láná, lónìí, àti títí ayé”. Nígbà tí ọ̀tá bá sì mú ọkàn nínú wọn pẹ̀lú àìsàn, ọ mọ àgbára Ọlọ́run.

Ẹ wo Dafidì kékeré, tí ó dúró níbẹ̀, ó sọ wípé, “Jagun-jagun ni ọkùnrin nnì láti ìgbà ìbí rẹ̀ wá. Àti láti ìgbà èwe rẹ, kò mọ ohunkóhun bíkòṣe ọ̀kọ̀ àti ìhámọ́ra. Ó jẹ́ ẹnití a kọ̀. (ó jẹ́ àkẹ́kọ́ nípa Ọlọ́run) ìwọ kò sì mọ ohunkóhun nípa èyí!

O sọ wípé, “Bẹ́ẹ̀ni, alágbà, n kò mọ ohunkóhun nípa ẹkọ nípa ọlọ́run tirẹ̀, ṣùgbọ́n ohun kan wa ti mo mọ̀: ohun nípé nígbà tí ọta wa láti gbé ọkàn nínú àwọn àgùntàn bàbá mi, mo lọ pẹ̀lú àgbára Ọlọ́run. Mo gbàá sílẹ̀! Mo mú padà bọ̀ sí ipò ìlera lẹ́ẹ̀kan sii, mo mú pàdà bọ́ sí pápá oko tútù àti omi díkákẹ́ rọ́rọ́. Ọlọ́run tí ó sì fi kinnìún lé mi lọ́wọ́, tí mo sì paá nígbà tí ó mú ọ̀kan nínú àwọn ọ̀dọ́-àgùntàn náà, tí ó sì mú mi pa Biarí náà, bẹ́ẹ̀ni Ọlọ́run ọ̀run yóò bá mi lọ láti pa aláìkọlà yìí!” a nílò ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́.

53 N kò mọ àwọn ọjọ́ aye mi, kò sí ẹnikan tí ó mọ̀. Ní òwúrọ̀ ọjọ́ kan, mo wà lórí ibùsùn. Mọ sì ti sùn, mo wá lá àlá wípé Joseph ṣe àìsàn, mo sì gbé lọ́wọ́ láti gbádúrà fún. Nígbàtí mo sì tají ará mi kò lélẹ̀. Mo wípé, 'Bóyá Joseph fẹ́ ṣe àìsàn“. Mo sì wò mo sì rí òjìjí kan tí ó ń lọ níwájú mí tàbí òjìjí aláwọ̀ amọ̀, ó sì dàbí ẹni pé èmi ni. Mo sì wòó, Ẹlòmíràn tí ó funfun sì ń bọ̀ lẹ́yìn, ó sì jẹ́ oun, mo wo ìyàwó mi wò, pé ṣé o ti ji kí n ba lè fi hàn fún, ó lè rí ìràn náà ṣùgbọ́n ó sì ń sun. mo sọ wípé ”Ah, ma tọrọ àforíjì Olúwa, ṣùgbọ́n bí ayé mi ti ṣe rí ni èyí, Ó ti ń ti mi láti ṣe ohun gbogbo tí mo ti ṣe. Ní ìgbàkúgbà tí ohun kan yóò bá ṣẹlẹ̀, mo rò pé ìwọ ni ó ti ń ṣe, mo sì wá mọ̀ wípé Satani ni kò jẹ́ kí ń rí ṣe“. Mo sọ wípé, ”Tí ó bá lè darí mi“. Bí mo sì ti ṣe wò, mo rí ìwò tí ó dùn ní wíwò tí eniyan lè rí ní ojú ọkùnrin kan. Ó dúró níwájú mi tí ó ń wo ẹyìn. Ó gbé awọ̀ Rẹ̀ sókè O sì gbà mí lọ́wọ́ mú O sì bẹ̀rẹ̀ sí níí bọ́ ní ọ̀nà yìí. Iran náà sì fi mí sílẹ̀.

54 Ní òwúrọ̀ ọjọ́ Àìkú tí ó kọjá, mo tètè jí, ó jẹ ní ọjọ́ Àbámẹ́ta, ìràn yìí. Ominú ti ń máa kọ mí, mo ti máa ń ronú ikú. Èmi, tí mo jẹ́ ẹni àádọ́ta ọdún, àkókò mi… N kò rò pé ó gun. Mo ti ń ronú pé báwo ni n o ṣe rí nínú àra òkè-ọ̀run, ara-ọ̀run. Ǹjẹ́ yóò jẹ́ wípé nígbà tí mo bá rí àwọn ọ̀rẹ mi iyebíye n o wá rí kúrukúru funfun tí ń lọ tí n o sì sọ wípé, “Arákùnrin Neville ni ó ń lọ yẹn”. Tí kò sì ní lè sọ pé, “pẹ̀lẹ́ o, Arákùnrin Branbam”? nígbà tí Jesu bá sì dé ni n o wá di eniyan pàdà. Mo ti máa ń ronú èyí.

Mo wá ńlá àlá wípé mo wà ní ìwọ̀-oòrùn mo sì ń sọ kalẹ̀ bọ̀ láti inú igbó kan, ìyàwó mi sì wà pẹ̀lú mi, tí a sì ń pa ẹja òṣùmàrè. Mo dúró mọ sì ṣí ilẹ̀kùn tí ilooro, ojú-ọ̀run sì dára púpọ̀. Wọn kò rí bí ó ti ṣe rí ní afonífojì ní ibíyí. Wọn jẹ́ àwọ̀ aró pẹ̀lú àwọ̀sánmà funfun. Mo sì wí fún ìyàwó mi pé, “ó yẹ kí a ti wà ní ibiyí ní ìgbà pípẹ́ ṣẹ́yìn, Oyin”.

O wípé, nítorí tí àwọn ọmọ, kò yẹ kí a ti wà, Billy“,

Mo sọ wípé, “Bẹ́ẹ̀…”

55 Mo sì jí dìde. Mo wá ronú pé, “Mo ń lá àlá púpọ̀ jù, è é ṣe tí ó fi rí bẹ́ẹ̀?” Mo sì wolẹ̀, ó sì tún wà ní ẹ̀gbẹ́ mi tí ó sùn. Mo gbára lé ìrọ̀rí mi, bí ọpọlọ́pọ̀ yín ti máa ńṣe, mo sì wa gbé orí mi lé ibi òkè ibùsùn àti ọwọ́ mi lẹ́yìn mi. Mo sì na ara síbẹ̀ báyìí. Mo wá sọ wípé; “Mo sì ti lẹ̀ wà nkọminú ohun tí yóò jẹ́, ní òdìkéjì lọ́hún. Mọ ti di ẹni àádọ́ta ọdún, n kò sì ti ṣe ohun kan síbẹ̀. Tí mo bá lè ṣe ohun kan láti fi ran Olúwa lọ́wọ́. Nítorí mo mọ̀ pé ń kì yóò jẹ́ eniyan ẹlẹran-ara… idájì ìgbà mi ti lọ, ó kéré tán, tàbí ju ìdajì lọ, tí mo bá lè gbé to iye ọdún àwọn eniyan mi, síbẹ̀ ìdájì ìgbà mi ti lọ, o kéré tán, tàbí ju ìdájì lọ. ”Mo sì wò yíká, mo sì wà lórí ibùsùn tí mo fẹ́ dide. Ó jẹ́ nǹkan bí agogo meje. Mo wípé, “Mo gbagbọ wípe n o lọ sí ilé-ìjọsìn ni òwúrọ̀ yìí, tí ohùn mi bá ti há, N o fẹ́

láti gbọ Arákùnrin Neville kò wàásù.

Mo sì wá wípé, “N jẹ́ o ti jí, Oyin?” O sì nsùn fọnfọn.

N kò si fẹkí ẹ pàdánù eléyìí, o tí yí mi pada. Ǹ kò lè jẹ́ Arákùnrin Branham ti tẹlẹ mọ.

56 Mo sì wò, tí mo sì gbọ́ ohun kan tí ó ń sọ wípé, “Ó ṣẹṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ni. Máa tẹ̀síwájú nínú ògùn náà. Sá máa tẹ̀síwájú”. Mo mi orí mi fún ìṣẹ́jú kan. Mo ronú, “Bóyá mo kan ń rònú lọ́nà báyìí ni, ṣe ẹ mọ̀pé eniyan lè ní ìwò-òye”, mo sì wípé, “Bóya mo kan n wòye èyí nnì ni”.

Ó wípé, “Tẹ̀síwájú ní ogun náà! máa lọ! Máa lọ!”

Mo sọ wípé, “Bóya èmi ló ń sọ èyí”,

Mo sì wá fi eyín mi di ètè mi mú, mo sì fi ọwọ́ mi bo ẹnu mi, bẹ́ẹ̀ni ohùn náà sì tún ni wípé, “sá máa tẹ̀síwájú, ti ó bá tilẹ̀ mọ ohun tí o wá lòpin ọ̀nà náà”. O sì dàbí ẹnipé mo lè gbọ́ Graham Snelling tàbí ẹnìkan tí ó ń kọ orin nnì báyìí; wọn máa ńkọ nibiyí - Anna Mac àti gbogbo yín:

Àárò ilé sọ mi, mo sì ń pòngbẹ mo sì fẹ́ rí Jesu;

N o fẹ́ kí àwọn agogo ebúté dídùn náà rò;

Yóò ṣe ìmọ́lẹ̀ sí ipa ọnà mi, tí yóò sì mú gbogbo ẹ̀rù lọ;

Olúwà, jẹ́ kí nwò kọjá ikélé akókó,

Ẹ ti gbọ ti wọn kọ ni ilé-ìjọsin yìí,

Mo sì gbọ ohun kan ti ó wípé,

“Njẹ́ ìwọ yóò fẹ láti wo kọja ìkélé àkókò náà bíí?

Mo sọ wípé, “yóò rànmí lọ́wọ́ púpọ̀”. Mo sì wo, ní iṣẹ́jú díẹ̀, èémí kan, mo tí dé ibikan tí ó tẹ́; mo sì wo ẹ̀yìn, níbẹ̀ ní mo sì wa lórí ibùsùn mi. Mo sì wí pé; “Èyí ṣe àjèjì”.

57 Nisisiyi, n kò ní fẹ́ kí ẹ tún èyí wí, níwájú ìjọ mi ni mo ti ń sọ èyí, tàbí àwọn àgùntàn tí mo ń ṣe olùṣọ́ fún. Bóyá mo ti jáde kúró nínú ara yi tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́, bóyá ó jẹ́ ìpaláradà… kò da bí ọ̀kan nínú àwọn ìran tí mo ti máa ń rí tẹ́lẹ̀. Mo lè wò lọ́hùn, mo sì tún le wo ibi yi nígbà kanna. Nígbàtí mo sì dé ibi kékeré náà, n kò ti ri ọ̀pọ̀ eniyan bẹ́ẹ̀ rí, tí wọn ń sáré wá, tí wọ́n sì ń kígbe, “oh, arákùnrin wa ọ̀wọ́n!” mo si wo, àwọn ọ̀dọ́mọbìnri bóyá bíi ẹni ogún ọdún, ẹni ọdún méjìdínlógún si ogún ọdún, wọn fi ọwọ́ wọn di mọ mi ti wọn sì ń kígbe pé, “arákùnrin wa iyebíye”.

Níbiyi ni àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin náà dé tí wọ́n si ń dán bi ìgbà-èwe wọn, tí ojú wọn si n tàn, tí wọ́n dàbí ìràwọ̀ nínú òkùnkùn òru, ẹyín wọn funfun bíi peali, wọ́n sì ń kígbe tí wọ́n di mọmi pẹ̀lú igbe, “oh, arákùnrin wa ọ̀wọ́n!” Mo sì dúrò, mo sì tún wo, mo sì ti di ọ̀dọ́. Mo sì n wo ara mi àtijọ́ mi lórí ìbùsùn pẹ̀lú ọwọ́ mi lábẹ́ orí mi, mo wá sọ wí pé, “Èyí kò yé mi.”

Àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin wọ̀nyí pẹ̀lú ń fi ọwọ́ wọn kọ́mi lọ́rùn.

58 Nisisiyi, mo mọ̀ wípé tọkùnrin-tobìnrin ni ó wà ni ibíyi, mo sì sọ èyí pẹ̀lú adùn àti ìdákẹ́rọ́rọ́ ti Ẹ̀mí. Àwọn ọkùnrin kò le fi ọwọ́ kọ́ àwọn obìnrin lọ́rùn kí ara eniyan ma mọ́ yàtọ̀. Ṣùgbọ́n kò sí níbẹ̀, kò sí àná tàbí ọ̀la, àárẹ̀ kò mú wọn. wọn kan….. n kò tii rí irú àwọn obìnrin tóní ẹwà bẹ́ẹ̀ rí láyé mi. Irun orí wọn gùn dé ìbàdí wọn, tòbí wọn gun de ẹsẹ̀ wọn, wọn sì ń di mọ́mi. Kò dàbí ìgbàtí arábìnrin mi tí ó jókòó níbẹ̀yẹn bá di mọ́mi. Wọ́n kò fi ẹnu kò mí ni ẹnu, èmí náà kò fi ẹnu kò wọ́n ní ẹnu. Ó jẹ́ ohun tí n kò ni ọ̀rọ̀-ńlá fun; N kò ni àwọn ọ̀rọ̀ láti sọ, pípé, kò le ṣàlàyé rẹ̀. Ó tayọ, kò le ṣàlàyé rẹ̀ lọ́nà kankan. Ó jẹ́ ohun tí n kò…. O ní láti wà níbẹ̀.

59 Wọ́n sì wo ìhín àti ọ̀hún, wọ́n sì ń wá ni ẹgbẹẹgbẹrun. Mo sì wípé, “Èyí kò yé mi.” Mo sọ pé, “Èéṣe, àwọn… nígbànáà ni Hope si de - ẹnití i ṣe ìyàwó mi àkọ́kọ́. Ó sáré, kò sí wí pé ”ọkọ mi“. ó wípé, ”Arákùnrin mi ọwọn.“ Nígbàtí ó sì di mọ mi, obìnrin mìíràn sì wa níbẹ̀ láti di mọ mi, Nígbànáà ni Hope si dì mọ́ obìnrin yìí àti mọ ara wọn… mo rò wípé, ”èyí ni láti jẹ́ ohun tí ó yàtọ̀, kò gbọdọ̀ ri bẹ́ẹ̀. Ohun kan wa…“ Ǹ jẹ́ n o ha fẹ́ padà si ogbologbo ara kíkú nni mọ bí? Mo wò káàkiri mo sì ronú pé, ”kínni èyí?“ Mo sì dùn wò púpọ̀, mo sì wípé, ”èyí kò yé mi“ ṣùgbọ́n Hope dàbí ẹni pàtàkì. Kò yàtọ̀ rárá, ṣùgbọ́n ó dàbí ẹni pàtàkì kan.

60 Mo sì gbọ́ ohùn kan tí o bámí sọ̀rọ̀ láti inú iyàrá náà, tí ó wípé; “Èyí ni ohun tí ó ti wàásù tí i ṣe Ẹ̀mí Mímọ́. Èyí ni ìfẹ́ pípé, kò sì sí ohun kan tí ó le wọ ibíyi láìsí eyi.

Mo wa pinnu ju ti àtẹ̀yìnwá lọ nínú ayé mi wípé ó gba ìfẹ́ pípé láti wọ ibẹ̀. Kò sí owú jíjẹ. Kò sí àárẹ̀, kò sí

ikú, àìsàn kò le wọ ibẹ̀ láyéláyé. Ẹ̀dá eniyan kò le jẹ́ kí ó di arúgbó, wọn kò si le sunkún. Ó jẹ́ ayọ̀ kan - “Oh, arákùnrin mi ọwọn.”

Nwọn sì gbé mi jòkóò ni ibi ńlá gíga kan. Mo sì wa ronú pé, “N kò lá àlá, ara mi ni mo sì ń wò tí ó dùbúlẹ̀ ní orí ibùsùn ni ibẹ̀ yẹn.” Nwọn sì gbé mi jókòó níbẹ̀ yẹn, mo sì wípé, “Oh, kò yẹ kí n jókòó nibiyi.”

Àwọn ọkùnrin àtobìnrin si ń wá láti ẹgbẹ́ méjèèjì, tí wọ́n wa ndán bi ọ̀dọ́, wọ́n ń kígbe. Obìnrin kan si dúró níbẹ̀ tí ó kígbe, “Oh arákùnrin mi ọ̀wọ́n. Oh, inú wá dùn púpọ̀ láti rí ọ ni ibíyi.”

Mo sọ wípé, “Eléyìí kò yé mi.”

Nígbànáà ohùn tí ó ń bámi sọ̀rọ̀ láti òkè wa sọ wípé; “Ṣèbí o mọ̀ wípé a ti kọ́ nínú Bíbélì wípé a kó àwọn wolii jọ pẹ̀lú àwọn eniyan wọn.”

Mo sì sọ wípé, “Bẹ́ẹ̀ ni, mo rántí nínú ìwé mímọ́.”

Ó sì wípé, “Èyí ni ìgbà tí a ó ko ọ jọ pẹ̀lú àwọn eniyan rẹ̀.”

Mo sì wí pé, “Nígbànáà wọn yóò wa nínú ara gidi, mo lè mọ wọn nínú ara mi.”

“Bẹ́ẹ̀ni o”

Mo wípé, “Ẹgbẹẹgbẹ̀rún ni àwọn wọ̀nyí. Ìdílé Branham kò pọ̀ tó báyìí.”

Ohùn náà si sọ wípé, “Àwọn ìdílé Branham kọ nìyí, àwọn tí ó jèrè fún Krístì nìyí. Àwọn tí ó darí sí ọ̀dọ̀ Olúwa ni.” O sì wípé, “Díẹ̀ nínú àwọn obìnrin tí ó rò wípé ó lẹ́wà púpọ̀ wọ̀nyí tilẹ̀ ju ẹni àádọ́run ọdún lọ nígbàtí ó darí wọn sí ọ̀dọ̀ Olúwa. Kò yanilẹ́nu tí wọ́n fi n kígbe pé, 'Arákùnrin wa ọ̀wọ́n.'

Gbogbo wọn si kígbe lẹẹkanaa, “Tí o kò bá ti lọ, àwa ki bá ti wa níbíyí.”

61 Mo wò yíká, mo sì rò wípé, “Èyí kò yé mi,” mo wa sọ wípé “oh, níbo ni Jésù wa? Mo fẹ́ láti rí I kánkán.

Wọ́n sì sọ wípé, “Nísisiyi, Ó wá lókè díẹ̀ sí ní ibẹ̀ yẹn”, wọ́n wípé, “Yóò tọ̀ ọ́ wá lọ́jọ́ kan”, wọ́n wípé, “A rán ọ jáde gẹgẹ́bí olórí kan, Ọlọ́run yóò sì wá, nígbà tí ó bá sì dé, yóò dá ọ lẹjọ́ gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó ti fi kọ́ wọn, lákọ́kọ́ náà, bóyá wọn yóò wọlé tàbí bẹ́ẹ̀kọ́. A o wọlé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kọ́ tí ó ti kọ́ wa”.

Mo sọ wípé, “Oh, inú mi dùndùn púpọ̀! Ṣe Paulu… n o ní láti dúró báyìí? Ṣe Peteru ni láti dúró báyí?”

“Bẹ́ẹ̀ni”.

Mo wípé “Nígbà náà, mo ti wàásù ohun gbogbo tí wọ́n wàásù”. Èmi kò yẹsẹ̀ kúrò níbẹ̀ sí ẹ̀gbẹ́ kan tàbí òmíràn. Níbi tí wọ́n ti ṣe Ìtèbọmi ní Orúkọ Jesu Kristi, mo ṣe bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú. Níbití wọ́n ti kọ mi ní Ìtẹbọmi Ẹ̀mí Mímọ́, mo ṣe bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú, ohunkóhun tí wọn fi kọni, mo ṣe bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú“.

Àwọn eniyan wọnnì sì kígbe wípé, “Awa mọ èyí, a sì mọ wípé awa yóò padà sínú ayé pẹ̀lú rẹ̀ ní ọjọ́ kan”, wọ́n wípé, nígbà tí Jesu yóò dé, a ó sì dá ọ lẹ́jọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ náà ti ó ti wàásù fún wa. Nígbà náà, tí a bá ṣe itẹ́wọ́gbà, èyí tí yóò rí bẹ́“, wọn sì wípé, ”Nigbà náà, ni ìwọ yóò fi wá fún-un gẹ́gẹ́ bí àwọn èrè iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ̀“. Wọ́n sì wípé, ”ìwọ yóò darí wá sọ́dọ̀ Rẹ̀ àti ní apapọ̀ a o padà sínú ayé láti máa gbé títí láé“.

Mo wípé; “Ǹjẹ́ mo ní láti padà báyìí?”

“Bẹ́ẹ̀ni, ṣùgbọ́n máa tẹ̀síwájú”.

62 Mo wo. Mo sì rí àwọn eniyan tí wọn sì ń bọ̀ wá láti ọ̀nà jínjìn réré ní bí mo ti ṣe lè rí mọ, tí wọ́n fẹ́ dì mọ́ mi, tí wọ́n ńkígbe, “arákùnrin wa ọ̀wọ́n”.

Nígbà náà, ohun kan sọ wípé, “gbogbo ẹnití ó nifẹ́ àti gbogbo ẹnití ó nifẹ rẹ, ni Ọlọ́run ti fún ọ níbíyìí”. Mo sì wò, níbẹ̀ ni mo ti rí ajá mi àtijọ́ tí ó ń rìn bọ̀ wá. Bẹ́ẹ̀ni mo rí ẹṣin mi tí ó rìn wá tí ó sì gbé orí rẹ̀ lé mi ní èjìká tí ó sì ń kígbe, wọ́n sì wípé, “gbogbo ohun tí ó nifẹ́, àti gbogbo ohun tí ó nifẹ́ rẹ ni Ọlọ́run ti fi lé ọ lọ́wọ́ nípasẹ̀ iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ̀”.

Mo sì bẹ̀rẹ̀ sí níí mọ wípé a ti ń gbàmí kúrò ní ibi dídára náà. Mo sì wo yíká, mo ní “ṣe o ti jí, Oyin?” O sì tún sùn, mo wá rò wípé, “Ọlọ́run o! Oh, ran mí lọ́wọ́, Ọlọ́run o, má ṣe jẹ́ kí n gba àbọ̀de pẹ̀lú ọ̀rọ̀ kan. Jẹ́ kí ń dúró ṣánṣán pẹ̀lú ọ̀rọ̀ náà kí n sì wàásù rẹ̀. N kò bìkítà ohunkóhun tí ó wù kí ó ṣẹlẹ̀, ohun tí ẹnikan lè ṣe, iye àwọn Saulu, àwọn ọmọ Kiiṣi, tí ó dìde, iye àwọn èyí, ìyẹn tàbí òmíràn, Olúwa! Jẹ́ kí n lè tẹ̀síwájú síi ibẹ yẹn”.

63 Gbogbo ẹ̀rù ikú… mo sọ èyí pẹ̀lú Bíbélì mi níwájú mi ní òwúrọ̀ yìí. Mo ní ọmọkùnrin kékeré kan níbẹ̀ yẹ, ẹni ọdún mẹ́rin, láti tọ dágbà. Mo ní ọmọbìnrin ẹni ọdún mẹ́sàn-án àti ọ̀dún kan tí mo dúpẹ́ fún, tí ó ti yípadà si

ọnà Olúwa. Ọlọ́run! Jẹ́ kí ń lè wá láàyè láti tọ wọn ní ìlànà Ọlọ́run. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ó dàbí ẹni pé gbogbo ayé ń kígbe sí mi. Awọn ẹni àádọ́rún-un ọdún lọ́kùnrin àti lóbìnrin àti onírúurú, "Tí o kò bá tí lọ ni, a kò bá ti wà níbíyìí". Ọlọ́run jẹ́ kí n lè tẹsiwaju ninu ogun náà. Sùgbọ́n tí ikú bá dé, tí ń kò sì mọ̀… yóò jẹ́ ayọ kan, yóò jẹ́ ìdunnú láti wọlé kúrò ní ibi ìdíbàjẹ́ àti ìtìjú yìí.

Tí ó bá lè ṣééṣe fún mi lókè lọ́hún láti ní ibùsọ ọgọ́rùn-ún bílliọ́nù kan, tí ògiri tí a kọ́, tí ó jẹ́ ìfẹ́ pípé. Gbogbo ìṣísẹ̀ ni ibiyí ni ó sì ńhá sí, títí a o fi dé ibi tí a wà nísisiyi. Yóò sì jẹ́ òjìjì ìdíbàjẹ́ lásán ni. Ohun kékeré nnì tí a lè mọ̀ nínú wa àti lára wípé ohun kan wà ní ibìkan, a kò mọ ohun tíí ṣe. Ẹ̀yin ọ̀rẹ́ mi iyebíye, ẹ̀yin olùfẹ́ mi, ẹ̀yin olólùfẹ́ mi nínú ìhìnrere, ẹ̀yin ọmọ tí mo bí fún Ọlọ́run, ẹ gbọ́ tèmi Olùṣọ́-àgùntàn yín. Ìbá wùmí kí ọ̀nà kan wà fún mi láti ṣàlàyé rẹ̀ fún yín. Kò sí àwọn ọ̀rọ̀ kankan. Ǹ kò lè ríi, a kò lè rí níbi kan, ṣùgbọ́n lẹ́yìn èémí ìkẹyìn yìí ni ohun tí ó lógo jùlọ tí ó ti lè…. Kò sí ọ̀nà láti ṣàlàyé rẹ̀. Kò sí ọ̀nà kan; N kò tilẹ̀ lè ṣe é. Ṣùgbọ́n ohunkóhun tí ẹ bá ń ṣe, ẹyin ọ̀rẹ́, ẹ pa ohun gbogbo tì sí apákan títí ẹ o fi ní ìfẹ́ pípé. Dé ibi tí ẹ ó fi lè fẹ gbogbo eniyan, gbogbo ọtá, ohun gbogbo. Abẹ̀wò kan tímo ní síbẹ̀ tí sọ mí di ọkùnrin ọ̀tọ̀. Ǹkò lè jẹ́ irú Arákùnrin Branham tí mo ti jẹ́ tẹ́lẹ̀ mọ́ láé láé.

64 Bóyá bàálù lè máa mì tìtì, bóyá mọ̀nàmọ́ná lè máa kọ mọ̀nà, bóyá àwọn aámín lè dojú ìbọn kọ mi, ohunkóhun tó wù kó lè jẹ́, kò jámọ́ nǹkankan. N o sì máa tẹ̀síwájú nínú ogun náà nípa oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nígbà tí mo ńwàásù ìhinrere fún gbogbo ẹ̀dá àti gbogbo eniyan tí mo lè wàásù fún, tí n o sì máa bẹ wọ́n fún ilẹ dídára náà lokè-lọhun.

Ó lè dàbí ẹni wípé ó le, ó gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ okun láti ṣe bẹ́ẹ̀. N kò mọ̀ bí yóò ti ṣe pẹ́ tó. A kò mọ̀, tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ti ara láti ibi ayẹ̀wò mi ní ọjọ́ yẹn, wọ́n sọ wípé "ó ti ní ọdún mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n igbé-ayé tí ó ti fi ṣe iṣẹ́ káràkárá. Ó jẹ́ ẹni takuntakun". Èyí rànmí lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n, èyí kọ́ ni mo ń sọ, ohun kọ́, ó jẹ́ ohun tí ó wà ní inú níbíyìí. Ara ìdíbajẹ́ yìí ni láti gbé àìdíbàjẹ́ wọ̀; ara kíkú yìí ni láti gbé ara àìkú wọ̀.

65 Àwọn ọmọ Kiiṣi le dìde, gbogbo ohun rere tí wọ́n lè ṣe, n kò ní ohun búburú láti sọ nípa rẹ̀ - fífún àwọn òtòṣì àti iṣoore, kí ẹ sì wá rántí wípé, Samuel sọ fún Saul wípé, "Ìwọ náà yóò sọ àsọtẹ́lẹ̀" ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọkùnrin wọnnì sì jẹ́ àwọn oníwàásù alágbára, wọ́n lè wàásù bí àwọn olórí-Angẹ́lì, ṣùgbọ́n síbẹ̀ kìí ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run. Ọlọ́run ni ó yẹ kí ó jẹ́ Ọba wọn. Arákùnrin, arábìnrin, ẹ jẹ́ kí Ẹ̀mí Mímọ́ darí yín. Ẹ jẹ kí a tẹrí wa ba fún ìgbà díẹ̀.

Arò ilé ńsọmí mo sì ń poǹgbẹ, tí mo sì fẹ́ rí Jésù,

Mo fẹ́ gbọ́ kí àwọn agogo ebúté dídùn náà dún,

Yóò tan ìmọ́lẹ̀ sí ipa ọ̀na mi, yóò sì lé gbogbo ẹ̀rù lọ;

Olúwa, jẹ́ kí a wo kọja ikele tí akoko náà,

Olúwa, jẹ́ kí ń wo kọjá ikele àwọn ìbànújẹ́ àti ẹ̀rù;

Jẹ́ kí ń lè wo ibi tí òòrùn tí ńta kedere nnì,

Yóò fi okun fún ìgbàgbọ́ wa, yóò sì lé gbogbo ẹ̀rù lọ;

Olúwa, jẹ́ kí wọn lè wo kọjá ikele tí àkókò náà.

66 O dámilọjú, Olúwà, tí ijọ kékeré yìí ba lè wo kọjá ikele náà ní òwúrọ̀ yìí,…kí yóò sí àrùn laarin wọn, tàbí tí yóò lè wa. Kí yóò sí àìsàn, ki yóò sí ohun kan bíkòṣe pípe. Ó sì jẹ́ èémí kan ní àárín, ibiyí àti ibẹ̀yẹn - láti ọjọ́ ogbó sí ọ̀dọ́, láti àkókò lọ sí àìnípẹ̀kun, láti àníyàn ọ̀la àti ìbànújẹ́ tí àná títí di àkókò yìí tí àìnípẹ̀kun nínú pípé.

Mo gbàdúrà, Ọlọ́run, wípé kí ó bùkún gbogbo àwọn eniyan tí ó wà ní ibiyí. Tí àwọn kan bá wà ní ibiyí, Olúwa, tí kò tíì mọ̀ Ọ ní ọ̀nà ìfẹ́ náà… ati òtítọ́, Baba, kò sí ohun tí ó lè wọ ibi Mímọ́ náà láìsí irú ìfẹ́ bẹ́ẹ̀ - àtúnbí, kí a tún eniyan bí. Ẹ̀mí Mímọ́ náà, Ìfẹ́ ni Ọlọ́run, awọn oke nípò nípa ìgbàgbọ́ wa, tí a sì ṣe àwọn ohun ńlá, síbẹ̀ láìsí nǹkan yìí níbẹ̀, a kì yóò lè gun àtẹ̀gùn nnì lókè-lọ́hún. Ṣùgbọ́n pẹ̀lú èyí nnì, yóò gbé wá sókè kọjá àníyàn ayé yìí.

Mo gbàdúrà, Ọlọ́run wípé, kí ó bùkún àwọn eniyan níbíyìí, sì jẹ́ kí gbogbo àwọn ẹni tí ó ti gbọ́ òtítọ́ tí mo ti sọ ní òwúrọ̀ yìí, tí ìwọ jẹ́ Ẹlẹ́rí mi, Olúwa. Gẹ́gẹ́ bí Samuel ti ìgbà àtijọ́, "N jẹ́ mo ti sọ ohunkóhun fún wọn ní orúkọ rẹ bíkòṣe òtítọ́ bí?" Awọn ni onídájọ́, mo sì wí fún wọn nísisiyi, Olúwa, wípé ó ti mú mi dé ilẹ̀ náa. Ìwọ mọ wípé òtítọ́ ni èyí. Njẹ́ nisisiyi, Bàbá, tí àwọn kan bá wà tí kò mọ Ọ́, jẹ́ kí èyí jẹ́ wákàtí náà tí wọn ó sọ wípé, "Olúwa, fi sínú ọkan mi ìfẹ́ náà láti lè ṣe ìfẹ́ Rẹ". Jẹ́ kó rí bẹ́ẹ̀, Bàbá.

67 Àti nísisiyi, ẹ̀yin tí ẹ tẹríba, ǹjẹ́ ẹ̀yin yóò gbé ọwọ́ yín sókè tí ẹ ó sì wípé; "Ẹ gbàdúrà fún mi, Arákùnrin Branham, Ifẹ Ọlọ́run nínú mi".

Nísisiyi, nígbà tí ẹ sì wà ní ibi tí ẹ wà, pẹ̀lú adùn ni tòótọ́, kinni ó dé tí ẹ kò fi sọ fún Baba wípé, "Ọlọ́run, ni ọkan mi, lóní mo kọ ohun gbogbo tíí ṣe ti ayé sílẹ̀. Mo gbà láti fẹ́ Ọ àti láti sìn Ọ́ fún gbogbo ayé mi. N o sì máa tọ Ọ́ lẹ́yìn láti ònì lọ nínú gbogbo ìwé Mímọ́ tíí ṣe Bíbélì Rẹ". Tí ó kò bá ti ṣe ìtẹbọmi lọ́nà ti ìtẹ̀bọmi Kristẹni, "N o ṣe bẹ́ẹ̀, Olúwa". "Tí nkò bá ti gba Ẹ̀mí Mímọ́…". Ìwọ yóò mọ tí ó bá gbà á. Yóò fún ọ ní… yóò fún ọ ní ìdánilójú àti ìfẹ́ tí ó nílò. Oo, o lè ti ṣe lòdì, tí ó ti ní ìjófòfò, o lè ti pariwo, tàbí fi èdè fọ̀, èyí tí ó dára, ṣùgbọ́n tí ìfẹ́ atọ̀runwá náà kò bá sí níbẹ̀… Gba mí gbọ́ nísisiyi.

Sọ wípé, "Olúwa, fi sí ayà mi àti ọkan mi fi ọwọ́ kàn Ẹmi Rẹ, kí nba lè ní ìfẹ́ àti ọ̀wọ àti ìfẹ́ àtọ̀runwá nnì nínú ọkàn mi lóní tí yóò mú mi lọ sí ilẹ̀ náà nígbà tí èémí ìkẹ́yìn bá fi mí sílẹ̀". Nígbà tí a o gba àdúrà, gbàdúrà fún ara rẹ nísisiyi ní ọ̀nà tirẹ, gbàdúrà. Bèèrè kí Ọlọ́run ṣe èyí fún ọ. Mo fẹ́ràn yin, mo fẹ́ràn yin, ẹyin ọkunrin ọ̀wọ́n pẹ̀lú ewú-orí tí ó jókó ní ibiyí, tí ó ti ṣiṣẹ́ takuntakun láti bọ́ àwọn ọmọdé; ẹyin mama àgbàlagbà tí ó ti nu omijé wọn nù kúrò lójú wọn. Jẹ́ kí n mú èyí dá yín lójú, arábìnrin ọ̀wọ́n, kò rí bẹ́ẹ̀ ní òdìkejì èémí lókè-lọ́hún. Mo gbagbọ́ wípé ó wà nínú iyàrá yìí ní dájúdájú. O kan jẹ́ ìpele kan tí a ń gbé ni; eléyí jẹ́ ìdíbàjẹ́ tí a ń gbé inú rẹ̀. "Mú kí ìfẹ́ Rẹ ti o wà ṣẹlẹ̀ nínú mi, Olúwa" gbàdúrà nígbà tí a ó gba àdúrà papọ̀.

68 Pẹ̀lú ọ̀wọ̀, Olúwa, lórí Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ àti Ẹ̀mí Mímọ́ Rẹ̀, inú wa dùn púpọ̀ wípé a mọ ibití ìbí wa ti wá. Inú wa nítorí pé a bí wa, kìí ṣe nípa ìfẹ́ ti eniyan, tàbí nípa ìfẹ́ ti ara, ṣùgbọ́n nípa ìfẹ́ ti Ọlọ́run. A sì gbàdúrà lóní, Baba, wípé àwọn wọ̀nyí tí wọ́n nbèrè fún oore-ọ̀fẹ́ ìdáríjì, wípé Ẹmí Rẹ yóò ṣe iṣẹ́ náà, Olúwa, kò sí ọ̀nà fún mi láti ṣeé. Eniyan lásán ni mí, ọmọ Kiiṣi míràn, ṣùgbọ́n a nílò Rẹ, Ẹ̀mí Mímọ́. Ọlọ́run, jẹ́ kí ń dàbí Samuel-ẹnití ó ń sọ òtítọ́ tí Ọ̀rọ̀ náà. O sì ti fi ìdí rẹ̀ mulẹ di isisiyi, mo sì gbàgbọ́ wípé Iwọ yóò tẹ̀síwájú níwọ̀n ìgbà tí mo bá ti dúró ní olótítọ́ pẹ̀lú Rẹ̀.

Jẹ́ kí gbogbo wọn gba ìyè àìnípẹ̀kun nísisiyi, Baba. Má ṣe jẹ́ kí ọjọ́ òní fi wọ́n sílẹ̀, jẹ́ kí èyí, ohun tí mo ti sọ fún wọn, di ògìdì. Àti gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe jókó gẹ́gẹ́ bí eniyan ẹlẹ́ran-ara lóní, tí a ń wo agogo wa, tí a ń ronú oúnjẹ wa, tí iṣẹ́ ọ̀là, tí àníyàn àti làálàá ayé, wọn kò ní sí mọ́ nígbà náà, gbogbo wọn ni yóò parẹ́ kúrò. Kò ní sí àníyàn mọ́ - ayọ̀ ńlá kan ti àìnípẹ̀kun. Fún wọn ni irú iyè bẹ́ẹ̀, Baba, olúkúlukù wọn sì jẹ́ kí… Mo béèrè èyí, Baba, wípé gbogbo ẹni tí ó wà níbí yìí ní òwúrọ̀ yìí tí ó ti gbọ́, ti mo sì ti sọ ìran yìí, jẹ́ kí nlé pàdé gbogbo wọn ní òdìkejì lọ́hún. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé àwọn ọkùnrin tí ó tako mi lè wá, àti àwọn obìnrin pẹ̀lú, ṣùgbọ́n, Bàbá, má ṣe jẹ́ kí èyí dúró ní ọ̀nà wa. Jẹ́ kí á lè pàdé wọn lọ́hún, tí wọn yóò sì sáré láti dì mọ́ ara wọn, pẹ̀lú ìgbé, "Arákùnrin wa ọ̀wọ́n". Jẹ́ kí ó rí bí a ti ṣe fihàn níbẹ̀, Olúwa, sí ẹnikọ̀ọ̀kan. Gbogbo ohun tí mo fẹ́ àti gbogbo ohun tí ó fẹ́ mi, mo gbàdúrà wípé kò rí bẹ́ẹ̀. Olúwa. Mo sì fẹ́ràn gbogbo wọn. Jẹ́ kí wọn farahàn, Baba. Mo fi ìyè àìnípẹ̀kun lọ̀ wọ́n báyí, jẹ́ kí wọn lè ṣe ipa tiwọn láti gbàá nítorí tí mo béèrè ní Orúkọ Jesu. Àmín

69 A ní àwọn ìgbà díẹ̀ láti gbàdúrà fún àwọn aláìsàn. Mo rí pé a ní ọmọdébìnrin kan ní ibíyí tí ó ṣe àìsàn àti omidan kan nínú kẹ̀kẹ́. Nísisiyi, sí ẹ̀yin arákùnrin mi ọ̀wọ́n jùlọ àti àwọn arábìnrin, ẹ dákun, ẹ má ṣe gbàmísódì. Nkò mọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀. Nkò mọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀. Ṣùgbọ́n Ọlọ́run, tí mo bá kù, jẹ́ kí npadà lọ sí ibẹ̀. Ṣáà jẹ́ kí nlọ sí ibi-àyé náà, ibẹ̀ ni mo fẹ́ wá, ibikíbi tí ó bá wù kó jẹ́. Nkò gbìyànjú láti dàbí Paulu ẹnití a gbà lọ sí ọ̀run kẹta. Nkò sọ èyí, mo gbàgbọ́ wípé O ń gbìyànjú láti mu mi lọkan le ní, O ńgbìyànjú láti fún mi ní ohun kékeré kún tí yóò mú mi tẹ̀síwájú nínú iṣẹ́-ìránṣẹ́ mi titun tó nbọ̀ lọ́nà.

70 Ǹjẹ́ yóò dàbí àìbọ̀wọ̀ fún yín tí mo má kà ohun kan fún yín fún ìṣẹ́jú kan? Ṣé yóò dára bẹ́ẹ̀? Ọ̀kan nínú àwọn ìwé ìròyìn tí ó ńléwájú ní orílẹ̀-èdè - Billy Graham: "Àwọn ẹlẹ́sìn Islam pe Dókítà Billy Graham", ó wà ní ojú-ewé àkọ́kọ́ ti ìwé ìròyìn "Afríkaans Times", ọjọ́ kẹ́ẹ̀dógún, oṣù kéjì, ọdún 1960. Ẹni tí ó kọ ìròyìn náà jẹ́ Mùsùlùmí (ọmọ-ẹ̀yìn Mohamadu) ó rò pé iṣẹ́ ìyanu gbọdọ̀ tẹ̀lé ìwàásù ìhinrere tí Kristì-ọ̀kan náà láná, lóní àti títí ayé. a ṣe àyọkà yìí:

"Ó jẹ́ Kristi náà yí tí ó ṣe ìlérí fún àwọn ọmọ-ẹ̀yìn Rẹ̀ nígbà tí ó sọ wípé, Ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà mí gbọ́, iṣẹ́ tí èmi bá ṣe ní yóò ṣe pẹ̀lú; àní iṣẹ́ tí ó ju èyí lọ ni yóò ṣe". Ǹjẹ́ ijọ ti ṣe àwọn iṣẹ́ tí… àwọn ìwà Kristi nínú Bibélì? Ǹjẹ́ o há lè ṣe bẹ́ẹ̀ lóní? Ǹjẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìjọ (ti ó jẹ́ ọ̀tọ̀) lè ṣe idajì nínú àwọn iṣẹ́ tí Kristi ti ṣe bí? Láìtí sọ nípa àwọn iṣẹ́ tí ó tayọ. Ǹjẹ́ ìwọ gẹ́gẹ́ bí ẹnìkan pàtàkì, agbẹnusọ àwọn Kristẹni, lè jí okú dìde sí ayé padà? Ǹjẹ́ o lè rìn lórí òkun? Ǹjẹ́ o lè wo aláìsàn sàn tí o sì fi ìtúnríran fún afọ́jú? Ǹjẹ́ eléyí kò há wà ní ìbámu pẹ̀lú ìgbà tí a sọ nípa Rẹ fún àwọn ọmọ-lẹ́yìn Mohammadu bí? Tàbí… ní ìgbéyẹ̀wó ohun tí Kristi sọ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ ìgbàgbọ́ rẹ̀?

71 Ni ìdáhùn sí ìròyìn Mùsùlùmú yí ni àwọn àṣiwí ti ṣe wáyé ní ọ̀kan-ò-jọ̀kan. Wọ́n tilẹ̀ ńtẹ̀bẹ̀lú Mùsùlùmí náà, ṣùgbọ́n ohun tó sọ tọ́. Èyí ni àwọn eniyan náà ní láti sọ:

"Ìdáhùn tí ó dára jùlọ nípa èyí tí a lè fi ka Bibelì àti ọ̀nà láti fi mọ Kuranì. Kùránì kò ṣe… kò ṣé fi ṣe àfiwé. Ohun tí àwọn ọmọ-lẹ́yìn Mohámọ̀dù ń sọ jẹ́ ohun tí ó yàtọ̀ tí ó sì takété sí Kristẹni, ó jẹ́ ohun tí a lè pè ní ọ̀rọ̀ b-o-m-b-a-s-t-i-c (ìtúmọ̀- ọ̀rọ̀ ìpọ́nko, mo rò bẹ́ẹ̀), èrò lásán. Ṣùgbọ́n ẹnití ó kọ ìròyìn ọhún ti tọ́ka sí ohun pàtàkì nípa àwọn iṣẹ́ ìyanu tí ó jẹ́ ti ìjọ. Ṣùgbọ́n síbẹ̀ a tún siyèméjì otítọ́ inú ẹnití ó kọ ìròyìn náà. Nítorí wípé tani ẹnití ó lè tọ́ka sí àléébù tàbí tí ó o lè ṣe àríyànjiyàn àwọn iṣẹ́-ìyanu ti Ẹni-ọwọ́ William Branham ṣe níwájú àwọn Mùsùlùmí ní Gúsù Áfríkà (South Africa) nígbà tí Ẹgbàárùn-ún gba Kristi gẹ́gẹ́ bí Olùgbàlà lábẹ́ iṣẹ́-ìránṣẹ́

William Branham ní ìlú Durban, Gúsù Afríkà (South Africa) àti ní àwọn ibòmíràn ní káàkiri gbogbo ayé, tàbí ti T. L. Osborn ní Ìlà-oòrùn Afrika (East Africa). Dájúdájú, a dúró gbọingbọin fún Billy Graham. Ní kókó ọ̀rọ̀ ìbéèrè náà- kókó ọ̀rọ̀ ìbéèrè yí kò ní iye lórí.

72 Láàrín gbogbo rẹ̀, ó sọ fún mi… wípé a gbà wèrè mọ́ ẹ̀sìn ní wà, a kò mọ̀ ohun tí á ńṣe, wọ́n tún ní láti jẹ́rí wípé Ọlọ́run ṣeé nínú ìwé ìròyìn wọn bí ó ti wù kí ó rí. Ọlọ́run sì tún jẹ́ Ọlọ́run lóní gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe jẹ́ tẹ́lẹ̀. Ẹ lè máa rò wípé wọn kò gbágbọ́, wọn kò ríi, kò farasin, a kò tilẹ̀ ṣe é ní kọ̀rọ̀ kan. Àwọn ẹgbẹ̀ẹ̀gbẹ̀rún lọ́nà ọgọ́rọ̀ọ̀rún eniyan ni ó jókó níbẹ̀ tí wọ́n sì rí nǹkan nắ, nígbà tí wọn rí abirun ọmọkùnrin tí ó yarọ nnì tí ó wà síbẹ̀, Ẹ̀mí Mímọ́ sọ fún nípa ìgbésí ayé rẹ̀ àti àwọn ohun gbogbo pẹ̀lú ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ níbẹ̀, tí wọn sì rí Ẹgbàárún Mùsùlùmí tí wọ́n dọ̀bálẹ̀ pátápátá tí wọn sì gba Jesu Kristi gẹ́gẹ́ bí Olùgbàlà lọkọ̀ọ̀kan.

A sì tún ní àwọn T. L. Osborn míràn àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ tí wọn fún àwọn àgùntàn ní oúnjẹ. Mo rò pé Arákùnrin Osborn kò ìtí dé àárín àwọn Mùsùlùmí rí. Wọ́n fọwọ́sọ̀yà wípé àwọn jẹ́ nǹkan, ṣùgbọ́n a sì tún ní Ọlọ́run kan tí ó lè gbà àgùntàn lọ́wọ́ Kinniún, tí ó sì lè gba agùntan kúrò lọ́wọ́ beari.

73 Ó sì wá ṣemí lóore láti mọ̀ wípé wọn ní láti kọ nǹkan yí tí wọn mọ̀ bẹ́ẹ̀. Wọn rìn kúrò, wọ́n sì kọ ẹ̀yìn wọn sí tí wọn sì sọ wípé, "ah! àwọn ọjọ́ wọnnì ti kọjá". Àwọn Musulùmí wọnnì wá sọ wípé; Ah! gbogbo Bibélì ti kọjá lọ nígbà náà, gbogbo yín kùnà, Ọkùnrin kan ni ẹ ńjọ́sìn fún. Ọkùnrin tí ó ti kú, orúkọ Rẹ̀ sì ni Jesu, ó sì ti kú ní àwọn ọdún pípẹ́ sẹ́yìn, kò sì sí ohun tí ó ńjẹ́ wípé o ti jíǹde.

Ṣùgbọ́n wọn kò lè sọ èyí nínú ìpadé ní Durban. Níbẹ̀ ni ó gbé dúró tí ó sì ńṣe ohun kan náà tí ó ti ṣe tí ó sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ fún wọn. Nísisiyi, àwọn ìjọ-àdámọ̀ ní láti padà wá… Ẹni náà tí ó kọ̀wé tí ó sì wí fún mi pé, mo ní láti fi ìdí ẹ̀kọ́ mi múlẹ̀ nínú Bíbélì, òun ni ẹni náà tí ó sì tún kọ èyí nínú ìwé-ìròyìn wọn. Ọlọ́run yóò mú kí wọn yìn-ín lógo bí ó ti wù kí ó rí, lọ́nàkọnà, ó dára bẹ́ẹ̀, yóò mú kí wọn yìn-ín lógo bí ó ti wù kí ó rí.

74 Ìwọ ni ọmọbìnrin kékeré kan tí ó ṣe àìsàn níbíyí, ṣé ọmọ rẹ ni bí? Kínni ìṣòro rẹ, arábìnrin? Ìsun-ẹ̀jẹ̀ nínú ọ̀pọlọ, ẹni ọdún mẹ́rin, ṣé ọmọbìnrin náà nìyí? Ohun kan ni ó wà, ìyá, tí ó lè gba ọmọbìnrin náà là, ohun ni Ọlọ́run. (Ìyá rẹ̀ sọ wípé; "ó tún sàn fún-un jù bí ó ti ṣe wà lọ") inú mi dùn fún èyí nnì. Arákùnrin Neville, ǹjẹ́ ìwọ ti sọ̀kalẹ̀ lọ láti gbàdúrà fún bí? Láti ìgbà tí Arákùnrin Neville ti lọ gbàdúrà fún ni ó ti yàtọ̀. A sì tún ní àwọn Olùṣọ́-àgùntàn ti wọn mọ oúnjẹ àwọn àgùntàn síbẹ̀.

75 Kínni ìṣòro rẹ, arábìnrin ọ̀wọ́n tí ó jókó lórí àga níbẹ̀ yẹn? Kínni tirẹ̀? Jẹjẹrẹ, Ó dára, tí n o bá bí yín ni ohun kan, bóyá níbí yìí, ẹni méló ni ó ti gba ìwòsàn kúrò nínú àrùn jẹjẹrẹ, ẹ gbé ọwọ́ yín sókè. Wo o bí arábìnrin.

Ọlọ́run ni olùwòsàn. A mọ bẹ́ẹ̀. Tí mo má sọ fún yín wípé mo lè lọ mú ìsun-ẹ̀jẹ̀ kúrò ní ọpọlọ ọmọbìnrin nnì, tí n o sì mú ní ara dá, ohun tó kùnà ni n o máa sọ fún yín o, tàbí wípé mo lè mú àrùn jẹjẹrẹ náà kúrò lára obìnrin náà. Ṣùgbọ́n mo mọ ohun kan; Beari ka wá, jẹjẹrẹ kan, iṣu-èèmọ̀ kan, ìfọ́jú kan, àní ikú pẹ̀lú tí ó ti gbé àwọn kan nínú àwọn àgùntàn Ọlọ́run ní ọjọ́ kan. Mo sì jáde lọ pẹ̀lú agbára Ọlọ́run, mo sì pà á, mo sì mú àwọn àgùntàn náà padà. Bẹ́ẹ̀ni, a ńlọ síwájú lóní, kì í ṣe pẹ̀lú ohun ńlá èyí tàbí tọ̀hún; mo jáde lọ pẹ̀lú kànnàkànà kékeré tí àdúrà lásán, yóò mú padà wá. Ṣé o gbà èyí gbọ́, tàbí bẹ́ẹ̀kọ́, arábìnrin? Ṣé ìwọ náà gbàgbọ́ bí, tàbí bẹ́ẹ̀kọ́, arábìnrin?

76 Ẹni mélòó nínú yín ni ó gbàgbọ́ pẹ̀lú ọkàn rẹ̀ báyí? Nísisiyi, ẹ tẹríba nígbà tí n o gbàdúrà. (Arákùnrin Branham kúrò ní orí ìtàgé-pẹpẹ láti gbàdúrà fún àwọn aláìsàn). Ó dára bẹ́ẹ̀.

Baba ọ̀wọ́n, arẹwa ọdọ́bìnrin tó dùbúlẹ̀ níbíyí tí kò lè rìn mọ́ tàbí lọ káàkiri, àfi tí O bá rán-án-lọ́wọ́. Ọta ti mú; ó ti kọjá ìrànlọ́wọ́ àwọn Dókítà ọta ti fàá lọ sí ọ̀nà-réré ní Okè-lọ́hún dé ibikan tí dókítà kò lè ṣe ohun kan fún. Ṣùgbọ́n kò kọjá ìkáwọ́ Rẹ̀. Olúwa, ó wà ní ibi tí ó ti lè gbé ọwọ́ Rẹ̀ léé. Lórí Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, mo gbé ọwọ́ mi lé-lé ọ̀dọ̀mọbìnrn náà tí mo sì fi ìsun-ẹ̀jẹ̀ ọpọlọ náà bu; ní Orúkọ Jesu Kristi, mo pè é padà sí ipò obìnrin pípé lẹ́ẹ̀kan sí. Yóò wà láàyè fún Ògo Ọlọ́run. Jẹ́ kí ara rẹ̀ dá, kí ó máa rìn wọlé, rin jáde ilé-ìjọsìn yìí gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹlòmíràn ti ǹṣe lẹ́yìn ìgbà tíwọ́n bá ti mọ Ọ́ tán. Ẹ yin Ọlọ́run lógo. Bẹ́ẹ̀ni yóò rí nípasẹ̀ Jesu Kristi…

77 Nípa ti irun rẹ̀ tí ó ti ńjá tí ó sì ń pàrọ̀ àwọ̀, ìgbà díẹ̀ ló kù tí yóò fi dé ilẹ̀ náà lókè-ọ̀hún níbití mo rí…? …tí kò sì ogbó mọ́, ṣùgbọ́n ọ̀dọ́, ṣùgbọ́n àwọn ololùfẹ́ rẹ wà níbi tí wọn sunkún nítorí pé wọ́n fẹran rẹ̀. Ọ̀tá ńlá kan ti gbá mú kúrò kọjá ibití Dókítà ti lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún-un, kìnniún - ìbẹ̀rù ti jẹjẹrẹ. Ọlọ́run, mo lépa rẹ̀ wà, mo sì wá láti mú-un pàdà. Mo pa kìnníún… ni orúkọ Kristi tí a kò rí ìríjú ẹnití èmi í ṣe. Jẹ́ kí ó fi í sílẹ̀, kí ara rẹ̀ sì yá láti lè gbé fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sí fún ọlá àti ògo Ọlọ́run nípasẹ Jesu Kristi Olúwa wa, àmín.

Baba wa ọ̀run, bí kìí ti ṣe pẹ̀lú ìhámọ́ra ńlá, tí kìí ṣe pẹ̀lú ọ̀kọ̀ tí ń dán, gẹ́gẹ́ bí ó ti wí…? …jáde wá ṣíwájú pẹ̀lú kànnàkànà kékeré ti ìgbàgbọ́. Mo wá fún ọ̀kàn àti ara yìí, tí ọta - jẹjẹrẹ ti gbá mú kọjá ibití Dókítà lè dé, ṣùgbọ́n mo jàdé wá ní òwúrọ̀ yìí, Olúwa, mo sì nmú padà sí ibi pápá oko tútù àti omi dídákẹ́ rọ́rọ́. Ní orúkọ Jesu, aṣẹ́gun ikọ̀ ẹnití èmi íṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́ tí kò lè kùnà mo gbàgbọ wípé a yóò mú padà pẹ̀lú agbára àdúrà yìí. Jẹ́ kó rí bẹ́ẹ̀ ní orúkọ Jesu…?

Mo gbàgbọ́ wípé ìsìn ìtẹ̀bọmi yóò wá nísisiyí?

Ǹjẹ́ ẹyin yóò gbé orí yín sókè fún ìgbà díẹ̀? Olùṣọ́-àgùntàn sọ fún mi nísisiyi wípé àwọn eniyan wọ̀nyí ṣe àìsàn púpọ̀púpọ̀, ara wọn yó yá. Ó dára, ilérí Ọlọ́run kò lè kùnà. A o lépa wọn lọ.

78 Wọ́n ní ìsìn ìtẹ̀bọmi, àwọn eniyan kan wà tí wọ́n fẹ́ máa lọ. A o ní ìsìn kan ní alẹ́ yìí. Ǹjẹ́ ẹnikan há wà tí kò ní lè wá sí ibiyí ní alẹ́ yìí tí yóò sì fẹ́ kí a gbàdúrà fún ọ nísisiyi? Tí kò ní lè wá ní alẹ́ yìí. Ǹjẹ́ ẹyin ó wá sí ibiyí nísisiyi? Ẹyin tí ẹ kò ní lè wá ní alẹ́ yìí. Ǹjẹ́ ẹyìn ó wá sí ibíyí nísisiyí? Ẹyin tí ẹ kò ní lè wá ní alẹ́ yìí, ǹ o ní ọpọ̀lọpọ̀ àkókò fún ilà àdúrà lálẹ́ yìí, wọn ní láti tẹ àwọn eniyan wọ̀nyí bọmí.

Nísisiyi, tí ẹ ó bá fún wa ní iṣẹ́jú kan tàbí méjì síi, nigba náà, a ó ṣe ìsìn fún ìtẹ̀bọmi, mo mọ̀ wípé ẹ o fẹ́ láti rí èyí, ẹyin tí ẹ sì fẹ́ ṣe ìtẹ̀bọmi ní òwúrọ̀ yìí, ó dára, ẹyin…obìnrin ẹ lọ sí ibẹ̀yẹn láti pààrọ̀ aṣọ yín, àti ẹ̀yin ọkùnrin ẹ lọ sí ẹgbẹ́ ibiyí nígbà tí mo ńgbàdúrà fún àwọn alàìsàn, ẹ lè máa múra sílẹ̀ fún ìsìn ìtẹ̀bọmi àti àwọn tí wọ́n fẹ́ nísisiyi.

79 Nísisiyi, ní alẹ́ yìí n o gbìyànjú láti ní ìlà àdúrà lálẹ́ yìí, lẹ́ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀, ní kété tí mo bá ti wọlé wá, aó sì bẹ̀rẹ̀ láti inú ìwé tí Efésù ní alẹ́ yìí. Inú wa yóò sì dùn púpọ̀ nísisiyi, láti gbà yín wọlé tí ẹ kò bá ní ilé-ìjọsìn tí ẹ ń lọ, ṣùgbọ́n tí ẹ bá ní olùṣọ́-àgùntàn àti ìjọ yín, nígbà náà ẹ lọ sí ilé-ìjọ́sìn iyebíye yín ní ibití ẹ ti ńkínwọnlẹ́yìn. Tí ẹ bá fẹ́ máa lọ àti tí ẹ sì ń tí padà lọ báyìí, kí Ọlọ́run bukún fún yín. Ẹ sì tún padà wá pẹ̀lú wa nígbà tí ẹ bá lè wá. Inú wa yóò dùn láti gbà yín. Nísisiyi, ẹ̀yin tókù nígbà tí ẹ wá ní ìtẹ́ríba fún ìṣẹ́gun kan, a fẹ́ láti gbàdúrà.

Baba, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ lóní fún kànnàkanna Olùṣọ́-àgùntàn kékeré náà, àdúrà tí ó mú kí kìnnìún kó wolẹ̀ lórí èékún rẹ̀, tí a sì gbà àgùntàn náà kúrò lọ́dọ̀ rẹ̀, padà sọ́dọ̀ àwọn mama àti bàbá rẹ̀. Mo gbàdúrà fún arákùnrin wa. Mo béèrè wípé kí ìwọ mú wọlé wá láìléwu pẹ̀lú, Olúwa, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ rírú náà àti àwọn ìṣòro àgọ́ ara rẹ̀ fií sílẹ̀. Mo jáde tọ̀ọ̀ lọ́ ọ, Olúwa, mú-un padà ní Orúkọ Jesù Kristì, bẹ́ẹ̀nii kó rí. Ọlọ́run yóò bùkún ọ, arákùnrin.

80 Bí mo ṣe ńlọ, mo rí ọmọdékùnrin kan tí ó fọ́jú, ohun kan tí mo fẹ́ láti sọ. Mo ṣe àìsàn gidigidi, tí mo sì nbì, mo wá ronú wípé (n kò fẹ́ kí ẹ pàdánù eléyí, tí ó bá ṣe e ṣe), Mo ronú wípé “Ọlọ́run kinni ń o fún-ni ti mo bá lè gbọ́ pé ẹnìkan dúró lóde”.

Tí ìyàwó mi yóò sọ wípé, “Billy, àgbàlagbà ọkùnrin-jẹ́ẹ́jẹ́ kan wà níbí yìí tí ó fẹ́ rí ọ”. níbíyí sì ni ọ̀gbẹ́ni apárí kan sì ti wọlé wá, pẹ̀lú irungbọ̀n funfun ní ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀.

Tí yóò wọlé wá tí yóò sì wípé, “Ìwọ ni Arákùnrin Branham bí?”

Tí èmi ó sì wípé, “bẹ́ẹ̀ni alàgbà, èmi ni”.

Orúkọ mi ni Símónì, “tó gbé ọwọ́ rẹ̀ lé mi tó sì wo mí fún ìṣẹ́jú kan, tó wá sọ wípé, ”Onígbàgbọ́ ní ọ́, Arakùnrin Branham“.

“Bẹ́ẹ̀ni”.

Ohun gbogbo ni yóò dára“. Simoni Peteru tí Bíbélì, báwo ni n o ṣe mọ rírì èyí tó! Kò ní lè sọ ohun púpọ̀-kò kan sá gbé ọwọ́ rẹ̀ lémi, yóò dara pátápátá.

Nígbà náà ni ohùn kan tọ mí wá wípé: nípa ìrànlọ́wọ́ Ọlọ́run àti nípa oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run, ẹgbẹ̀ẹ́gbẹ̀rún mẹ́wá àwọn eniyan ló gbà ohun kan náà gbọ́ tí n o bá tọ wọ́n lọ. Tí mo sì rò pé “Olúwa, jẹ́ kí ńlè dé ọ̀dọ̀ gbogbo àwọn ẹnikọ̀ọ̀kan tí mo bá lè dé. Nígbà náà, jẹ́ kí n saa…” Mo ronú wípé tí Simoni yóò bá…Paulu, díẹ̀ nínú wọn yóò bá wọlé wá, tí yóò wípé “ṣé ìwọ ni Arákùnrin Branham?

“Bẹ́ẹ̀ni”.

Tí wọn yóò gbé ọwọ́ wọn lé mi, tí wọn yóò sì wo mí, tí wọn yóò sì sọ wípé, “Ó dára bẹ́ẹ̀, Arákùnrin Branham”, tí wọn yóò sì rin jadé lọ. Ará mi yóò yá. N o wà nípò tó dára. Dájúdájú, mo sọ wípé, “Ọmọkunrin, máa ní ìgbóyà ní kankan nígbà náà”. N o sọ wípé, “Ara mi yóò yá, Bẹ́ẹ̀ ni alàgbà, àwọn eniyan wa lóní tó gba nǹkan-kan náà gbọ́, ohun tí mo sì ńbọ̀ wá láti ṣe ní alẹ́ yìí ni èyí: gbé ọwọ́ lé yín, kí ń sì béèrè lọ́wọ́ Ọlọ́run.

81 Mo fẹ́ lọ sí ọ̀dọ̀ ọmọkùnrin kékeré yìí, arábìnrin, laarin ìṣẹ́jú kan, ọmọkùnrin afọ́jú kékeré yìí, ó tó ìgbà wo tí ó ti fọ́jú, arábìnrin? Láti ìgbà ìbí rẹ̀. Ọmọkùnrin kékeré yìí. Oh! Ìwọ kọ́ ni…? Nísisiyi fún ìṣẹ́jú kan.

Ọlọ́run olóòre, ó kọjá ohun tí àwọn Dókítà lè ṣe, láti igbà tí wọ́n ti bí ọmọkunrin yí, wọ́n bí ní afọ́jú, ti kò sì lè ríran, kò lè rí, ọmọkùnrin kékeré tí ó rẹwà, tí ó sì wuni yìí… Tí ọtá, kí ọmọdé náà tó rí ààyè nínú ayé, ó ti dàgbà kọjá ohun tí àwọn Dókítà lè ṣe. Ṣùgbọ́n mo ńlépa rẹ lówúrọ̀ yíì Oluwa. Kànnàkànnà kékeré tí adura yìí…? Jẹ kí n le gbà á padà, Ọlọ́run. Mo sì pàdé ọta, eṣu, ni orúkọ Jesu Kristi, mo sì mú ọmọkùnrin yi padà fún Ọlọ́run. Mo gbà ojú rẹ padà fún Ọlọ́run, fifun padà ohun tí satani ti jígbé kúrò lọ́wọ́ rẹ̀. Jẹ kí ó rí gbà ní

orúkọ Jesu Kristi, bẹ́ẹ̀ni yóò rí. Nisisiyi, ko rí bẹ́ẹ̀.

Nisisiyi, arábinrin, ọ̀wọ́n, má ṣe ní wóró àìgbàgbọ́ kan, nítorípé ara ọmọdékùnrin naa yóò ya. Mo fẹ́ kí o mu pada wá sínú ilé-ijọsin yìí láti fi hàn àwọn eniyan wípé ó ti ríran…? …fún ní ìràn rẹ ni orúkọ Jesu Kristi…?

82 Bẹ́ẹ̀ ni…? …Jesu Olúwa…? …ọmọ kékeré yìí tí a ti gbà àdúrà púpọ̀ fún, ṣùgbọ́n ní òwúrọ̀ yìí mo wá lẹ́ẹ̀kansí ní Orúkọ Jesu Kristi, pẹ̀lú kànnàkànnà kékeré tí ó fún mi; ó ti ràn mí lọ́wọ́ pẹ̀lú èyí, Olúwa, nípa agbara Rẹ láti mú… láti ẹnu…? ..láti ẹnu ikú fúnrarẹ̀, tí ó ti jí okú dìdé nígbà tí wọ́n ti kéde rẹ̀ pé ó ti kú, tí ó sì ti gbẹ, tí o tutù nini. Mo tọ ọ̀tá yìí wá, ní orúkọ Jesu Kristi. Nítorí náà, mú pada wá sí ipo ìlera lẹ́ẹ̀kan sí i. Gba bẹ́ẹ̀, jẹ́ kó rí bẹ́ẹ̀ fún ogo Ọlọ́run.

O sì ní láti gbàdúrà fún… ṣé onígbàgbọ́ ni ọ́? Olúwa, mo mú wa sí ibi ti kànnàkànnà kékeré yìí ti le gbà mú. Ní orúkọ Jesu Kristi jẹ́ kó fii sílẹ̀ kí ó sì máṣe pada wá mọ́. Àmin…?...

Ó dára, kànnàkànnà kékeré náà tí ó jáde lọ tí ó sì lọ mú ọkàn náà, àti fún ọmọbìnrin rẹ, tí…? … Bába ọ̀run ọ̀wọ́n, mo jáde tọ ọ̀tá wá, mo ń lo kànnàkànnà kékeré yìí tí ó fi fún mi, nítorí pé O sọ wípé tí o bá lè mu ki àwọn eniyan gba ọ́ gbọ́ tí ó sì ṣe olótítọ́ nígbà tí ó bá gbàdúrà…? … lọ nísisiyi gẹ́gẹ́ bí mo ti ṣe ran lọ fún ẹbẹ àdúrà rẹ ní orukọ Jesu Kristi jẹ́ kó rí bẹ́ẹ̀, Àmín

83 Ó dára bẹ́ẹ̀ arábìnrin. Nísisiyi, a fẹ́… Àìfọ̀kanbalẹ̀ kọjá ohun tí àwọn dókítà lè ranni-lọ́wọ́ fún. Wọ́n lè fún ọ ní ohun tí yóò mú ọ dákẹ́ fún ìgbà díẹ̀, ṣùgbọ́n yóò tún burú sí lẹ́yìn ìgbà náà…? …kíyèsí, a ń jáde tọ̀ ọ́ lọ ní owúrọ̀ yìí, a ń jáde lọ láti mú padà wá. (Ẹ̀rọ ko sọ̀rọ̀ mọ́)

Jesu Oluwa (ẹ̀rọ kò sọ̀rọ̀ mọ́) Mo …. (ẹ̀rọ kò sọ̀rọ̀ mọ́) marun un (ẹ̀rọ kò sọ̀rọ̀ mọ́) àwọn òkúta kékeré, Ì-GB-À-GB-Ọ́, nínú kànnàkànnà àdúrà, mo sì nmú arabìnrin mi padà kúrò lọ́wọ́ àìsàn àìfọ̀kanbalẹ̀…? … àwọn dókítà…? … Mo ń mú padà bọ̀ wá sí àlááfíà àti pàápàá oko tútù àti omi dídákẹ́ rọ́rọ́; mo sì ṣe èyí ní orúkọ Jesu Kristi Àmín…?

Ó dára bẹ́ẹ̀, kì í ṣe àìlókun-ara tó, Baba Ọlọ́run, ọmọbìnrin kékeré yìí, inú wa dùn púpọ̀ wípé kìí ṣe àìsàn àìlókun-ara tó ni; ṣùgbọ́n láìbìkítà ohun tí ó lè jẹ́, ó sì tún wà ní ìkáwọ́ Rẹ, Olúwa, mo sì wà pẹ̀lú kànnàkànnà kékeré kan nínú kànnàkànnà yìí…? …Mo sì ju òkúta yìí pẹ̀lú gbogbo agbára tí mo lè lò láti fi jù ú, ní orúkọ Jesu Kristi kí ó kọlu ú ní ojú òpó. Jẹ́ kí arábìnrin wa kékeré gba ìmúláradá. Mo ṣe èyí ní orúkọ Jesu Kristì…?

84 Gẹ́gẹ́ bí ọ̀dọ́-ìyá yìí àti ọmọ rẹ̀ kékeré, ẹni-kékeré tí ó fẹ́ pàdé ní òdìkéjì òkè-lọ́hun, ní ilẹ̀ ológo náà tí mo ṣẹ̀ṣẹ̀ sọ̀rọ̀ rẹ̀. Àti àwọn… àwọn ìyá kì yóò máa bí ọmọ láti tọ́ mọ́. Bákan náà, ọ̀dọ́mọdé náà kò lè gbé lọ titi láìsí ìrànlọ́wọ́ Rẹ̀, ṣùgbọ́n mo ń bọ pẹ̀lú kànnàkànnà yí, pẹ̀lú gbogbo agbára nínú èrò nnì tí mo lè fi mú ọ̀tá. Ní orúkọ Jesu Kristi, mo ju kànnàkànnà yí síi. Ara wọn yóò yá fún ogo Ọlọ́run. Ní orúkọ Jesu Àmín.

Oh, ó dára púpọ̀, inú mi dùn, nítorí pé iṣẹ́-ìránṣẹ́ náà jẹ́ iṣẹ́-ìránṣẹ́ ńlá kan tí ó ń tọ́ka wọn sí…? Yóò burú sí fún-un? Bàbá wa ọ̀run, Satanì ti gba ìyá kékeré yìí kúrò ní ìkáwọ́ àwọn dókítà lọ́hún. Wọ́n kàn lè mú kànnàkànnà òògùn wá fún mi, Olúwa, eléyí kàn lè mú ìdàrúdàpọ̀ wá fún tí kò sì ní mọ ibi tí ara rẹ̀ kù sí mọ́, nígbà tí ó bá sì tún yá, yóò tún burú sí fún. Ṣùgbọ́n mo ń bọ̀ wá pèlú kànnnàkànnà ìgbàgbọ́ pẹ̀lú òkúta tí à ńjù pẹ̀lú èrò tó bámu, láti lè bá ohun náà bí ó ti yẹ. Ní orúkọ Jesu Kristi, mo mú àìfọ̀kanbalẹ̀ yìí kúrò fún ògo Ọlọ́run.

85 Ọlọ́run ọ̀wọ́n, Arákùnrin George tí ó wà ní ìdùbúlẹ̀ tí ó sì ń kú lọ ní àìpẹ́, ẹ wo ohun tí ìgbàgbọ́ ṣe fún-un. Nísisiyi, ó ní àrùn làkúrègbé, Olúwa o mọ̀ wípé wọ́n lè fún ohun ní Kọ́tisonnù (cortisone) tàbí ògùn míràn tí yóò dín ìrora náà ku, ṣùgbọ́n kò ní mú kúrò, nítorí náà, a fi àdúra yi ṣe ìpinnu ní orúkọ Jesu Kristi, jẹ́ kí làkúrègbé náà kúrò. Jẹ́ kí ó lọ sí ilé pẹ̀lú ara dídá. Ẹ ṣeun lọ́pọ̀lọpọ̀…?

Ṣe dáradára ni, Oh, bẹ́ẹ̀ni, mama, ǹjẹ́ o gbọ́ gbogbo rẹ̀ bí? Lẹ́yìn ìkélé tí ẹran-ara ìbátan. Ṣé onígbàgbọ́ ni ọ́ nínú Jesu Olúwa? Mo rí obìnrin tí ó lẹ́wà níbẹ̀…? …ọdọ̀ ni iwọ yoo wà títí láé. Mo mọ̀ wípé ẹ fẹ́ gbé e nísisiyi fún ògo Rẹ̀. Ó nlo kánkán sí ibòmíràn…? …ọmọkùnrin rẹ… o kò lè rí bí? Oh, ko ṣe é ṣe fún ún…? … ìròbìnújẹ́ ló mú ọ, mo rí.

Arábìnrin ọwọ́n, mo fẹ́ kí o rí… …níbi yìí. Ǹjẹ́ o wà níbí yìí…? Ó dára bẹ́ẹ̀, ìwọ ó sọ fún. Ó dára, yóò sọ fún ọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ wípé ní ikọjá èémí rẹ, ọmọkùnrin iyebíye náà ń dúró dè ọ́. Ìwọ náà yóò jẹ́ ọ̀dọ́ bí tirẹ̀…? … ni…?...

Baba ọ̀run ọ̀wọ́n, o ti sá eré ìje ìgbé-ayé, kò sí ohun tí ó kù mọ́, àti ọmọkùnrin rẹ̀ iyebíye ní ìkọjá odò. Ó kàn lè wo ẹ̀yin padà…? Ni…? Ó ń dúró dẹ ọ̀kọ̀-ojú-omi náà, Olúwa, tí yóò mú la ìgba-ìrọwé já, lọ sí ilẹ̀ ológo náà, ìwọ bùkún fún-un, Baba…? …ọkàn rẹ̀. Jẹ́ kí eléyí lè jẹ́ ìdàpọ̀ ńlá, ní òkè odò náà.

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7